# Bi Mo Ti Wa Pẹlu Mose, Bẹẹni Emi Yoo Wa Pẹlu Rẹ

Jeffersonville, Indiana, USA

Ọjọ Kọkanla, Oṣu Kẹsan, Ọdun 1960

1 .... A jade lẹẹkansi ni owurọ yi, lẹyin ti a ti sun daradara ni òru. Mo nireti pe gbogbo wa ni a sun daradara, ti a si ni imọlara itura loni. Mo n roo, bi mo ṣe n duro ninu iyara ... Billy Paulu pe ẹni ọdun mẹẹdọgbọn loni. Mo ranti bi mo ṣe duro ni ori pẹpẹ yi kannaa nigbati Frankier Weber .... Aladugbo wa nihin, oun ati emi nlọ si ile iwe papọ. Mo si jẹ nkan bi ẹni ọdun mọkanlelogun tabi mejilelogun nigbana, mo gbagbọ bẹẹ, oun si ti pe ẹni ọdun mẹẹdọgbọn. Nigbati o si pe ẹni ọdun mẹẹdọgbọn, mo ro o pe, “Ah, akiika, Frankie ti fẹ ku, o ti dagba.” Ati nisisiyi ... Mo ro o nigbana pe, “Ki ni emi yoo ṣe nigbati mo ba de ọjọ ori yi, ọdun mẹẹdọgbọn? Nisisiyi, ọmọ mi pe ẹni ọdun mẹẹdọgbọn.

Eyi n fihan pe akoko nlọ, ko si duro de ẹnikankan. A gbọdọ siṣẹ nigbati imọlẹ wa, nitori akoko kan mbọ nigbati a ko ni lee siṣẹ mọ. Mo si maa n fẹran Orin Iye Longfellow, “Pẹlu ìyára, gbe igbe aye rẹ, ko ipa ti aye ko lee gbagbe.” A gbọdọ la ipa, nigbati a lee ṣe bẹẹ, ẹnikọọkan wa. Ẹ maṣe jẹki a fi ọjọ kan ṣòfò, ṣugbọn ki a ṣe amulo gbogbo ọjọ bi a ba ṣe lee ṣe to fun ogo Rẹ.

2 Ni aṣalẹ ọjọ diẹ sẹyin, tabi ọsẹ meji sẹyin, .... Oluwa fi awọn iran kan han, bi gbogbo wa ṣe mọ eyi nihin. Mo si ri iran ajeji kan nigbati mo wa ni ilu Kentucky. Mo sọ fun awọn eniyan ti o wa pẹlu mi, pe, “Dajudaju, ohun kan fẹ ṣẹlẹ.”

Mo ri ọkunrin kan to duro niwaju mi, ni nkan bi agogo mẹta òru ninu iyara, o dudu pupọ. Dudu tirẹ ki i ṣe bi ti awọn arakunrin ati awọn arabinrin wa ti o jẹ alawọ dudu; ti ọkunrin yi yatọ. Ara rẹ jẹ kiki irin, o si mbọ pẹlu ọwọ rẹ ti èèkànnáá rẹ gun lati mu mi, aabo ti emi si jẹ abẹfẹlẹ. Ṣugbọn ko dara to, ko lee ... Nko lee daabo bo ara mi pẹlu rẹ. Ni ọna kan, Oluwa sọkalẹ wa, O si ran mi lọwọ lati bọ lọwọ ọkunrin buburu yi. O jẹ kiki irin. Mo lee ri i bi o ṣe gbe ọwọ rẹ soke, pẹlu ara rẹ ti o hunjọ, ti o da bi irin to n rin lọ siwaju ati ẹyin. Mo ro o pe, boya, ọta ti o le ko ni lee wọ inu awọ ara rẹ (ti o da bi ti iru ẹranko kan, bi ijapa tabi ohun miran) ti o bo o. O si n le mi. Mo ni ero rere lori ohun ti iyẹn jẹ ati itumọ ti o ni.

3 Ṣugbọn ni owurọ ọjọ Iṣẹgun ti o kọja, ni nkan bi agogo mẹta, ohun miran ṣẹlẹ. Mo wa ni ile, ẹnikan si n duro niwaju mi ti O jẹ Ẹni atọrun wa to n sọ ọrọ ti nko loye. Akoko ti O da si ti sunmọ. Nko si gbọ ọ daradara, ṣugbọn Ẹni mimọ latoke wa ni. O si wipe, “Ni ọjọ meje si akoko yi, iwọ yoo duro gẹgẹ bi Mose ti duro,” tabi “iwọ yoo da bi Mose,” tabi ohun kan ti o jẹmọ Mose. Ọjọ naa yoo si pe ni ọ̀tunla. Iyẹn ni ikẹfa. Nko mọ ohun ti eyi tumọsi. Mo mọ pe Oun yoo mu un ṣẹ, ohun to wu ki o jẹ. “Iwọ yoo duro,” tabi “iwọ yoo ni lati duro,” tabi “iwọ yoo da bi i, tabi .... Ohun ti o ni i ṣe pẹlu Mose ni. Nko si ro pupọ nipa rẹ. Mo sọ fun ẹbi mi, mo si sọ fun awọn olufẹ mi kan. Sibẹ, o sọrọ bi eniyan.

Lẹyinnaa, mo sakiyesi pe ninu iwaasu mi ti aṣalẹ ana, Oluwa mu mi yàn lati sọrọ nipa Mose. Ni owurọ yi, o jẹ Mose ati ẹniti Oluwa yàn lẹyin iku rẹ. Iwe Mimọ ti mo fẹ fi sọrọ ni owurọ yi dá lori Mose ati Joshua. Iwe Mimọ yi, ni ori kinni Iwe Joshua, O maa n jẹ Iwe Mimọ ti o ta-yọ. Nko waasu lori rẹ ri ni aye mi; n o gbiyanju lati ṣe bẹẹ ni owurọ yi.

4 Ṣugbọn ni nkan bi ọdun meji sẹyin, mo ri Bibeli, ninu iyara, ti O sọkalẹ wa, ti O si n duro sibi ti mo wa. Ọwọ kan sọkalẹ lati oke, O si ṣi Bibeli naa, O ṣi awọn oju ewé Iwe Mimọ naa; O si ṣi Iwe Joshua ori kinni, ẹsẹ kinni si ikẹsan, O si duro, o nlọ diẹdiẹ. Mo ti duro fun wakati yi lati de, ninu eyiti n o ni imọlara pe ifẹ Ọlọrun ni fun mi lati sọrọ lori rẹ.

Bayi, ẹ maṣe gbagbe isin aṣalẹ, ti o ba lee wa, ti iwọ ko ba ni ibi-iṣẹ lati lọ. Ti o ba ni awọn ile ijọsin ti o nilo rẹ, eeṣe, a ó sọ fun ọ lati lọ si ile ijọsin rẹ.

Ni owurọ yi, a o gbadura fun awọn alaisan, ni kete ti a ba ti waasu tan. Mo si ro pe, lẹyin eyi ni a o ṣe iribọmi fun awọn eniyan.

Ni aṣalẹ yi, bi Oluwa ba fẹ, mo fẹ waasu lori awọn idanimọ Iwe Mimọ marun ti a fi n da ijọ mọ, ati ajọsepọ wa pẹlu rẹ - Pẹlu Ijọ Majẹmu Titun yi. Isin yoo si bẹrẹ, a o bẹrẹ orin kikọ ni agogo meje-abọ; n o gbiyanju lati bọ si ori pẹpẹ ni agogo mẹjọ. A o si pari ni agogo mẹsan-abọ, bi Oluwa ba fẹ.

5 Lẹyinnaa, mo ni igbẹkẹle pe loni, ki yoo jẹ ọ̀kan ninu awọn ọrọ wọnyi ti ... Nigbati mo ba wọ inu aṣẹ naa ti a fifun mi lọ, pe ẹnikẹni ko ni kuna lati ri i, nitoripe o ṣe pataki pupọ lati pa ohun gbogbo ti bayi, ki ẹ si ronu, bi a ṣe n duro de Ẹmi Mimọ.

Ki a to wọ inu Ọrọ iyebiye ati Ọrọ oloore-ọfẹ yi, n o beere fun ọrẹ mi tootọ ati alabasiṣẹ pọ mi, Dokita Lee Vayle, ti yoo ba dide ki o si dari wa ninu adura, bi a ṣe n si Ọrọ naa. Arakubnrin Vayle. [Arakunrin Vayle n gbadura.] O ṣeun, Arakunrin Vayle, fun adura ti o ni imisi ti o gba si Ọlọrun.

6 Ati nisisiyi, ẹ jẹki a ṣi Bibeli wa. Ọpọlọpọ ohun ni a ni lati sọrọ le lori, sibẹ, bi a ti n ri ọpọlọpọ awọn eniyan

to n duro ti ogiri ati ninu gbọngan, ati bẹebẹẹ lọ. Mo gbagbọ pe a n wọ igba-ọtun. Bayi, fun kika Iwe Mimọ ni owurọ yi, ẹ jẹki a ṣi Bibeli wa si Iwe Joshua ori kinni. A o ka lati inu Iwe Joshua ori kinni, ori kinni, bẹrẹ lati ẹsẹ kinni de ikẹsan.

Nigbati a n mura lati ka a ... A n ka iwaasu yi silẹ, yoo si lọ si ọpọlọpọ orilẹ ede agbaye. Emi yoo fẹ ki awọn eniyan ni agbaye, loju awọn ti Ọlọrun ti fun mi ni ojurere, ti mo si ri oore-ọfẹ ni oju yin, mo n sọ eyi ni owurọ yi, nitoripe ni ọjọ iwaju mo nireti pe n o wa si apejọ̀pọ yin fun ipade, ki ẹ lee mọ ohun ti Oluwa ti ṣe siwaju akoko naa, ki ẹ lee mọ otitọ. Ati bi Jesu ti sọ, “Otitọ yoo sọ yin di ominira.”

7 Mo n ka lati inu Iwe Joshua ori kinni:

O siṣe lẹhin iku Mose iranṣẹ OLUWA, ni OLUWA sọ fun Joshua ọmọ Nuni, iranṣẹ Mose, wipe

Mose iranṣẹ mi ku; dide goke Jordani yi, ati gbogbo eniyan yi, si ilẹ ti mo fifun wọn, ati fun awọn ọmọ Israẹli

Ibi gbogbo ti atẹlẹsẹ yin ba tẹ: ẹyin ni mo fifiun, gẹgẹ bi mo ti sọ fun Mose.

Lati aginju, ati Lebani yi, ani titi de odo nla ni, odo Euferate, gbogbo ilẹ awọn Hiti, ati titi de òkun nla ni iwọ-oorun, eyi ni yoo ṣe opin ilẹ yin.

Ki yoo si ọkunrin kan ti yoo lee duro niwaju rẹ ni ọjọ aye rẹ gbogbo gẹgẹ bi mo ti wa pẹlu Mose, bẹẹ ni Emi o si wa pẹlu rẹ: Emi ki yoo fi ọ silẹ, bẹẹni Emi ki yoo kọ ọ.

Ṣe giri, ki o si mu aya le: nitori iwọ ni yoo pin ilẹ naa fun awọn eniyan yi, ilẹ ti mo ti bura fun awọn baba wọn lati fifun wọn.

Ṣa a ṣe giri ki o si mu aya le gidigidi, ki o si mu aya le gidigidi, ki iwọ ki o lee kiyesi ati ṣe gẹgẹ bi gbogbo ofin ti Mose iranṣẹ mi ti palaṣẹ fun ọ: maṣe ya kuro ninu rẹ, si ọtun tabi si osi, ki o lee dara fun ọ nibikibi ti iwọ ba lọ

Iwe ofin yi ko gbọdọ kuro ni ẹnu rẹ, ṣugbọn iwọ yoo maa ṣe aṣaro ninu rẹ ni ọsan ati ni oru, ki iwọ ki o lee kiyesi ati ṣe gẹgẹ bi gbogbo eyiti a kọ sinu rẹ̀; nitori nigba naa ni iwọ yoo ṣe ọna rẹ ni rere, nigba naa ni yoo si dara fun ọ.

Emi ko ha paṣẹ fun ọ bi? Ṣe giri, ki o si mu aya le, maṣe bẹru, bẹẹni, ki aya ko maṣe fo ọ nitoripe OLUWA Ọlọrun rẹ wa pẹlu rẹ nibikibi ti iwọ ba nlọ

8 Ni ẹsẹ karun, ati ni nkan bi aarin ẹsẹ naa, a kọ ọ sibẹ pe: “Bi mo ti wa pẹlu Mose, bẹẹni Emi o si wa pẹlu rẹ.” Eyi ni ohun ti, n o ba pe e ni akori kan, ti n o ni lati duro fun iṣẹju diẹ, ki n si pe akiyesi yin si i. “Bi mo ti wa pẹlu Mose, bẹẹni Emi yoo wa pẹlu rẹ.”

Bayi ni aṣalẹ ana, a n rin irin-ajo pẹlu awọn ọmọ Israẹli lati ilẹ Egipti titi ti a fi de Kadeshi. Ah, iru ẹkọ wo niyi! Iru nkan nla wo ni ó jẹ, bi a ṣe n fi ijọ ara ṣe afiwe ijọ ẹmi. Ọlọrun n ṣe pẹlu awọn ọmọ Israẹli ninu ara; pẹlu ijọ ni ọjọ oni, bi O ti n pe awọn eniyan jade fun orukọ Rẹ laarin awọn Keferi. O n ṣe pẹlu wọn nipa ti ẹmi, bi O ti n ṣe pẹlu wọn nipa ti ara. Wọn nfi ẹ̀gbẹ́-kẹ̀-gbẹ́. Ohun gbogbo ti Ọlọrun ṣe pẹlu wọn, ati ohun gbogbo ti Ọlọrun ṣe fun wọn, ati ohun gbogbo ti wọn ṣe pada, wọn tọ wa wa fun apẹrẹ. A si ri i, pe, a ti ṣe Ọrọ naa bakannaa: bi o ti jẹ pe nipa ti ara, nigbati iwọ gba iṣẹgun tabi ni ọna mejeeji, wọn n fidi-kalẹ lati ṣe ajọyọ, wọn si n pariwo ayọ, wọn n jo, wọn n yin Ọlọrun, bi ijọ pẹlu ti ṣe; wọn si ti duro nisisiyi fun ogoji ọdun fun ṣíṣí ohun miran.

9 Bi a ti n ro nipa Mose, iranṣẹ Ọlọrun nla yi, bi o ti jẹ pe ni akoko ìbí rẹ, nibi ìbí rẹ, Ọlọrun yan an fun iṣẹ ti a dá a fun, nigbati a bi i. Igbe aye rẹ̀ ko si rọrun fun un lati gbe nitoripe eniyan ni, o si fẹ gbe e ni ọna kan, Ẹmi Ọlọrun si n dari rẹ ni ọna miran. Iru ìyàn omugọ wo ni yoo jẹ fun un, lati ṣe, nigbati, o ku igbesẹ kan fun un lati gun ori itẹ lati di ajogun aye, ti o si yan lati di ẹni itanu, alarinkiri. Ti a ba ro o nipa ọgbọn ori, yoo jẹ iṣe omugọ.

Ṣugbọn a ri ẹkọ nla kan nihin, pe awọn eniyan ti o n tẹle idari Ẹmi jẹ omugọ si aye, nitoripe wọn jẹ ti ijọba miran, a n dari wọn ni ọna miran, a n dari wọn nipa ti Ẹmi. Ọlọrun jẹki eyi jẹ emi tabi iwọ, pe ki a tẹle idari Ẹmi Ọlọrun botiwu-kori, ki a maa kiyesi ileri Ọlọrun, ki a si maa duro de imuṣẹ rẹ.

10 Eyi si ni ohun ti Mose ṣe gẹlẹ. Farao ka Iwe Mimọ kannaa ti Mose ka, ṣugbọn Farao wo o ni ọna miran. Mose wo awọn eniyan kannaa ti Farao ri. Farao ri wọn bi ẹrú ati awọn ti n ge bíríkì; Mose ri wọn bi awọn ti a pe, ti a si yànfẹ́.

Bi emi pẹlu ṣe fẹ ri ijọ Ọlọrun alaye niyi. Ki i ṣe bi awọn alakata-kiti tabi ẹni-ìtanù, ṣugbọn bi ayanfẹ Ọlọrun, ki n lee fi aye mi jì, bi Mose ti ṣe, fun ijọ nla yi ati fun iṣẹ ihinrere.

Bayi a ri Mose ti a pe. A ti lẹyin ti a ti fi aṣẹ fun un, o já aṣẹ ti a fifun un kulẹ nipa bi o ṣe n gbiyanju lati ṣe e ni ọna ti o ro pe o dara ju.

Nitorina, eyi kọ wa pe a ko lee ṣee ni ọna ti a ro pe o dara ju, tabi ohun ti eniyan ro pe o dara ju. A ni lati yan ọna ti Ọlọrun sọ pe o dara ju. Nitorina, lati tẹle Ọrọ Ọlọrun, ni ọna ti o daraju. Rin ni ọna ti Ọlọrun la silẹ.

11 Ninu ikuna rẹ̀, a ri i pe o sa kuro niwaju Farao lọ si aginju nibiti o ti fẹ Sipporah ti i ṣe ọmọbinrin Jetro. Lẹyin ti o si fẹ ẹ tan, obinrin naa bi ọmọkunrin kan fun un, ti orukọ rẹ njẹ Gershomu. O si fidi-kalẹ jẹẹ ati ni Alafia, ninu iṣẹ darandaran.

Ṣugbọn ni ọjọ kan, Ọlọrun gbọ igbe awọn eniyan Rẹ. Ọlọrun ranti pe Oun ba awọn eniyan naa da majẹmu kan. Ki i ṣe iyẹn nikan, ṣugbọn o ranti pẹlu pe Oun ni iranṣẹ kan, ẹniti O ti pe, ti O si ti yan, O si ni majẹmu kan pẹlu iranṣẹ naa. Ọlọrun ko si ni yí majẹmu Rẹ pada, tabi ki O yi ifẹ ọkan Rẹ pada, tabi ki O yi ohunkohun ti O sọ pada. Nigba-gbogbo ni Ọlọrun yoo maa pa awọn ileri Rẹ mọ. Bi o tilẹ jẹ pe Mose ti ja Ọlọrun kulẹ, ti o si ti ṣe ohun ti o lodi, sibẹ, Ọlọrun pa Majẹmu Rẹ mọ. Nigbati Ọlọrun ba pe eniyan kan lati ṣe ohun kan, o ni lati ṣe e, dandan ni ki o ṣe e.

12 Ẹnikan bi mi nigbakan, pe, “Ṣe ki a wa ẹbun iṣẹ iranṣẹ wa nisisiyi?” Ará kan lati ijọ Mẹtọdisi ti o ṣẹṣẹ gba Ẹmi Mimọ.

Mo sọ pe, “Rara, maṣe ṣe bẹẹ. Nigbati o ba ṣe bẹẹ, Ọlọrun ko lee lo ọ.” Mo wipe, “Ohun ti o ni lati ṣe ni ki o tẹsiwaju lati maa jẹ Kristẹni. Ti Ọlọrun ba pe o, yoo fi ọ si ibiti o yẹ ki o wa ninu ara Rẹ̀.”

Bi o ti maa njẹ, awọn ti o n wa, ti o si n gbiyanju lati ni nkan, ti Ọlọrun yoo ba fun wọn ni nkan, wọn yoo jẹ agberaga. O maa nri bẹẹ pe, eniyan ti Ọlọrun pe ni eniyan to n gbiyanju lati sa fun Un, ti ohunkohun ba wa - Mose ati Paulu, ati oriṣiriṣi awọn eniyan bẹẹ, wọn maa n gbiyanju lati sa fun ipe naa.

13 A ri i nihin pe Ọlọrun, pẹlu gbogbo ikuna ti Mose ti ṣe, ọwọ Ọlọrun si wa lara rẹ sibẹ. O si pe e lati lọ ṣe iṣẹ Rẹ, O pe e si iṣẹ iranṣẹ rẹ. Ati iru imọkanle ti eyi yoo ti jẹ fun Joshua nigbati o gbọ ti Ọlọrun sọ pe, “Bi mo ṣe wa pẹlu Mose, bẹẹni Emi yoo wa pẹlu rẹ.”

Bi mo tilẹ n gbiyanju ti mo si n kuna, Ọlọrun ko ni fi mi silẹ. Nko ni igbẹkẹle pupọ ninu ẹnikẹni to n bẹru lati ṣe ohunkohun. N o yàn lati kuna, ju ki n ya ọlẹ ti ko lee gbiyanju lọ.

14 Nigbakan, a gbọ ọ pe ile-isẹ iyẹfun Ballard gba osiṣẹ kan, o si ni lati kọ orukọ ara rẹ; ọkunrin naa ko si ni ohun ti a fi n pa àsìkọ rẹ nidi pẹnṣu rẹ. Bẹẹ ni Ọgbẹni Ballard sọ fun un pe, “Eeṣe ti iwọ ko fi ni eroja to n pa àsìkọ rẹ?”

Ọkunrin naa wipe, “Emi ki i ṣe asiṣe.”

Ọgbẹni Billard si wipe, “Nigbana, emi ko lee lo ọ. Nitori ti o bạ se asiṣe .... ti iwọ ko bạ se asiṣe, iwọ ko ni ṣe ohunkohun.” Otitọ ni.

Ọlọrun ki i ba eniyan wi fun asiṣe rẹ. Ẹ̀ṣẹ̀ ti o mọ-mọ da lo n ba ọ wi fun. “Ẹnikẹni ti o ba mọ-mọ dẹṣẹ lẹyin ti o ti gba imọ otitọ ...” Ṣugbọn eniyan ti yoo ṣe ohun kan, yoo kuna, yoo ṣubu. Yoo sị se asiṣe. Ṣugbọn ti a ba pe nitootọ latoke wa, ti Ọlọrun si wa ninu ọkan rẹ, yoo dide lẹẹkansii.

15 O maa n ṣẹlẹ pe, awọn kan ti wọn maa n wa si sọọsi yi ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin (wọn si lee wa nihin ni owurọ yi), ọkunrin kekere kan ati iyawo rẹ. Wọn maa nkọ orin kan to maa n wu mi lori, o lọ bi eyi:

Dariji mi, Oluwa, ki O si lo mi lẹẹkansi,

Emi yoo jẹ tire, ti Iwọ yoo ba jẹ ti emi;

Ti mo ba ṣubu tabi mo kuna, jẹki n dide,

Ki n si gbiyanju lẹẹkansi,

Dariji mi, Oluwa, ki O si danmi wò mi lẹẹkansi

Mo fẹran iyẹn, gbogbo ọmọ-ogun rere ni o lẹtọ lati gbọgbẹ tabi fi ara-pa. Ṣugbọn ti o ba si jẹ ọmọ-ogun ti o si ni idi kan tabi ohun kan lati ja fun, yoo dide, yoo si gbiyanju lẹẹkansi. Eyikeyi ọmọ ogun agbelebu tootọ yoo ṣe ohun kannaa.

16 Ati si Joshua, ẹnitiṣe olori awọn ọmọ ogun naa, lẹyin ti Mose ti ku, bi o ti rii pe Ọlọrun duro ti i ninu asiṣe rẹ, o di aṣẹ ti a fun un mu ....

Ohun towu ki Mose ti ṣe, ipo ti Ọlọrun fi Mose si ni Ọlọrun bọwọ fun. Wolii ni. O gaju gbogbo awọn wolii yooku lọ. O gaju eyikeyi wolii ti wọn ti ni lọ. Nigbati arabinrin rẹ fi i ṣe yẹyẹ nitoripe o fẹ ọmọbinrin ara Etiopia kan, Ọlọrun pe wọn papọ, O si sọ pe, "Ṣe ẹyin ko bẹru Ọlọrun ni? Pe, "Ti ẹnikẹni ba wa ninu yin ti i ṣe ẹni ẹmi tabi ti o jẹ wolii, emi yoo ba sọrọ ninu iran, N o si fi ara Mi han si i nipa àlá. Ṣugbọn eyi ko ri bẹẹ pẹlu Mose. Emi n ba a sọrọ ni ẹnu ko eti ni. Ṣe ẹyin ko bẹru Ọlọrun ni?"

Ṣe ẹ rii, iyẹn ki i ṣe ohun rere, lati ri awọn eniyan Ọlọrun fín. Iwọ n mu Ọlọrun binu nigbati o bą se bẹẹ. Ọlọrun ti fi aṣẹ fun Mose. Ikuna rẹ ko ni itumọ - Ọlọrun mọ ọkàn rẹ.

17 Nigbakan, Mose ṣe awa-wi lori bi o ṣe n ni ọpọlọpọ ojuṣe lati ṣe. Bẹẹni Ọlọrun mu Ẹmi Rẹ, O si pin-in si aarin awọn aadọrin. Ki i ṣe pe Ẹmi Ọlọrun ti wọn ni nigbana ju eyiti wọn ni ni ibẹrẹ lọ, ṣugbọn ohun ti o wa nibẹ ni pe, awọn osiṣẹ ti pọ sii. Odiwọn Ẹmi kannaa ni.

Ọlọrun lee fi gbogbo Ẹmi Rẹ sinu ọkunrin kanṣoṣo ti O ba fẹ, tabi ki O pin laarin ẹgbẹẹgbẹrun ti O fẹ bẹẹ. Ni igba kan O fi gbogbo Ẹmi Rẹ sinu eniyan kan ti a n pe ni Jesu; bayi, O ti pin in si aarin ijọ Rẹ nibi-gbogbo. Ọlọrun n pa aṣẹ Rẹ mọ.

18 Bayi, Joshua, jagunjagun tuntun. Awọn meji pere lo ṣẹku bayi ti o de ilẹ ileri. Eyi ni Joshua ati Kalẹbu. Bayi, Joshua ti i ṣe balogun tuntun ti yoo dari ọmọ ogun kan, lati gba ipo ti eniyan nla bi Mose duro si, ki i ṣe iṣẹ ti o rọrun.

Mo ronu nipa iranṣẹ Ọlọrun kan loni ti Ọlọrun pe lati ṣe iṣẹ iranṣẹ kannaa ti Jesu ṣe - iru aṣẹ wo niyi, iru ìpè wo niyi. Ṣugbọn ẹnikọọkan eniyan ti a pe lati ọdọ Ọlọrun ni a fi aṣẹ fun lati duro si ipo kannaa. "Emi yoo wa pẹlu yin, a ni ninu yin, titi de opin." Gbogbo iranṣẹ Ọlọrun ni a pe lati duro si ipo ti O duro si: "Iṣẹ ti Emi ṣe ni ẹyin pẹlu yoo ṣe." Ẹnikọọkan iranṣẹ ti Ọlọrun yan ni a palaṣẹ lati duro si ipo Jesu Kristi, ki wọn o siṣe ojuṣe Jesu. Iyẹn jẹ aṣẹ!

19 Bi ko ba ti ri nigbati Joshua n duro sibẹ ni owuro ọjọ naa, to n ba Ọlọrun sọrọ, Ọlọrun wipe, "Emi ki yoo ja ọ kulẹ; bi mo ṣe wa pẹlu Mose, bẹẹni Emi yoo wa pẹlu rẹ, ki yoo si ẹnikẹni ti yoo lee duro niwaju rẹ ni gbogbo ọjọ aye rẹ. Emi yoo pa wọn run, bẹẹ ni N o fọn wọn ka. N o mu ki ọna naa là, ṣe giri ki o si mu aya le. Maṣe fòyà [iyẹn ni aniyan]. Maṣe bẹru, Emi yoo wa pẹlu rẹ! Emi yoo mu ọ laaja." Iru aṣẹ naa ti a fifun ọkunrin tuntun ti a n pe ni Joshua yi.

Bayi, orişirişi afiwe lo wa ninu eyi, ti a lee sọrọ le lori, ṣugbọn a o fo awọn kan ninu wọn ru. Fun apẹrẹ, bi Mose ti jẹ igba ijọ ti o ko wọn de Sinai, si ibi ẹkọ Bibeli wọn (ti aṣalẹ ana). A ko gba Mose laye lati ko awọn ọmọ Israẹli de ilẹ ileri nitoripe o ti kuna.

20 Awọn agbekalẹ ijọ, awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ ti kuna. Wọn ko ni lee ko ijọ de ilẹ ileri! Ọlọrun yoo gbe ilana tuntun dide, eyiti o tayọ ijọ ẹlẹyameya, nipa agbara Ọlọrun, ti yoo mu ijọ de ilẹ ileri. Awọn agbekalẹ ati awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ ti ṣe idibajẹ ohun gbogbo, ikọọkan wọn n tẹle ẹkọ adamọ ti ijọ rẹ, ikọọkan n tẹle irori tirẹ. Ṣugbọn Ọlọrun yoo mu Ẹmi Mimọ Rẹ, yoo si gbe Joshua Rẹ dide, eyiti yoo mu ijọ de ilẹ ileri, laisi okùn adamọ ti a so o nibikibi, ṣugbọn yoo mu ijọ Rẹ de ilẹ ileri.

Mose ti kuna. O jẹ ẹniti o mu ofin wa. A pe Joshua nipa ore-ọfẹ, o si nko ijọ lọ si ilẹ ileri.

21 A ri i pẹlu pe Joshua, bi oun ti mọ aṣẹ ti a fifun un yi, bi o ti mọ pe ẹru naa wa ni ejika oun, ninu eyiti ko gbọdọ kuna, o rin jẹjẹ niwaju Ọlọrun. Nigbati o si pe awọn eniyan naa papọ, ti o si sọ fun wọn pe Ọlọrun ti fi aṣẹ fun oun, ẹ sakiyesi ibeere awọn eniyan naa. Wọn wipe, "A o tẹle ọ bi a ti ṣe pẹlu Mose ti a ba lee ri ohun kannaa ti o tẹle Mose ki o maa tẹle ọ. Ṣe giri, ki o si mu aya le."

O yẹki eyi jẹ amuyẹ ẹniti o ti di atunbi loni. Ti a ba pe wa lati tẹle e, nigbana, ẹ jẹki a ri àmì naa to n tẹle onigbagbọ. Bi Jesu ti ṣe, "Iṣẹ ti Emi ṣe ni ẹyin pẹlu yoo ṣe."

Mo si ti sọ fun yin tẹlẹ lati ri daju pe ọkan ẹmi yin ṣi silẹ ni owurọ yi, nitori mo n ni igbẹkẹlẹ pe ẹ o loye ohun ti mo n sọ. A n joko pẹlu awọn eniyan lati oniruru ijọ, orişirişi ẹgbẹ lo korajọ sihin ni owurọ yi, lati ijọ Katoliki ati Alatako ati orişirişi, bẹẹni a o fihan si awọn ti a kun fun Ẹmi, nitootọ.

22 Bayi, Joshua ni lati gba aṣẹ yi. Awọn eniyan naa wipe, "Ki Ọlọrun wa pẹlu rẹ bi O ti wa pẹlu Mose, awa yoo si mọ pe Ẹmi kannaa ti O dari wa de ihin yoo mu wa laaja."

Ah, bi o ti yẹki ijọ wo o ni owurọ yi lati ri Ẹmi to n rin laarin awọn eniyan, ti ẹ ba n fẹ ijọ nibiti Ẹmi ti O gbe Kristi dide kuro ni ipo oku, Ẹmi Mimọ, eyiti yoo rin laarin awọn eniyan. Eyi ni Ẹmi ti Ọlọrun n gbe dide ni ikẹyin ọjọ lati mu awọn eniyan de ilẹ ileri, si inu ẹkunrẹrẹ ibukun Ọlọrun, ati si imuṣẹ aṣẹ ti O fifiun wa, tabi ileri naa. "Si yin ni ileri naa ati si awọn ọmọ yin." Bi Israẹli ṣe wa ilẹ ileri naa, bi wọn ti mọ pe o wa nibikan nitoripe ẹnikan ti lọ sibẹ tẹlẹ, bẹẹ ni ijọ pẹlu! A mọ pe ilẹ kan wa nibikan! Agbara kan wa nibikan nitoripe awọn kan ti

wa nibikan. A mọ pe ilẹ naa wa ni oke odo, nibiti awa nlọ ni owurọ yi, ti a n gbiyanju lati lọ si ilẹ ileri naa.

Joshua mọ pe ilẹ naa wa nibẹ. O ti kọkọ lọ, o si ri i, lẹyinnaa ni o lee pada wa bi ẹlẹri.

Awọn iranṣẹ ti Ọlọrun pe ni ko yẹki o gan pẹlu ẹkọ adamọ, ṣugbọn o yẹki wọn o ti ṣe abẹwo si ilẹ ti a nlọ, ki wọn o maa mu ẹri ifẹ atoke wa ati agbara Jesu Kristi lati sọ ọ di mimọ si ijọ wọn pe ilẹ kan wa ti o wà nikọja odo naa.

23 Bayi, iwaasu aṣalẹ ana n sọ nipa lilọ si Jordani. Bayi, nigbati a ba de ibi odo naa, yoo pin wa niya. Yoo ya wa sọtọ. Ni ikọja odo naa, ohun kan ti ṣẹlẹ si ọ.

Bayi, Joshua, ninu gbogbo eyi, bi o ti mọ pe aṣẹ naa lagbara, ṣugbọn ti o ni idaniloju, o lee lọ lai-bẹru, o lee ri bẹẹ, bi a ti lee sọ ọ, yoo lọ lai bikita-niwọn igbati a ba tọka ọna ti o yẹ sii. O lee dojukọ oke ti o lee daa pada si ẹyin, ṣugbọn o nlọ ni ọna ti o tọ́.

Bẹẹni ijọ Ọlọrun alaye lee lọ lai bikita tabi lai bẹru ninu igbagbọ ti a ba tọka ọna ti o yẹ si wa; nitoriti O sọ pe, “Bi mo ti wa pẹlu Mose, bẹẹni Emi yoo wa pẹlu yin. Emi ki yoo ja ọ kulẹ bẹẹni Emi ki yoo kọ ọ silẹ.” Ko kọ Mose silẹ ri. Ko ja Mose kulẹ ri. Oun ko ja Joshua kulẹ. Oun koni ja wa kulẹ! Oun yoo wa pẹlu wa.

24 Bi a ti ri Joshua ti yoo gba iṣẹ iranṣẹ yi, bi o ti mọ pe ojuṣe oun ni lati dari awọn ọmọ Israẹli la ilẹ naa kọja ... yoo ni lati lọ si ilẹ naa. Yoo ni lati ṣe agbekalẹ ijọba wọn. Yoo ni lati pin ini wọn laarin wọn, O mọ pe iṣẹ naa tobi pupọ, o pọ ju ohun ti Mose ti ṣe lọ. Ojuṣe ti Joshua ní lati ṣe pọ, ju eyiti Mose ni lati ṣe lọ.

Ohun miran, o ni lati dari wọn lọ si aala ilẹ naa, laarin awọn ará wọn. Wọn tọ ẹ̀jẹ̀ wò. O ni lati bori wọn, o ni lati pawọ́n lẹnu mọ bi wọn ṣe nlọ.

Bẹẹni o ri loni pẹlu awọn ẹgbẹ onigbagbọ tuntun to n fi ifedefọ ṣe ijẹri Ẹmi Mimọ, to n dide lakoko yi. Wọn ti tọ iṣe ijọ ẹlẹkọ adamọ wo. O lagbara pupọ lati de wọn mọlẹ.

25 Ni awọn ọdun diẹ sẹyin, wọn sọ pe, “Wa, Arakunrin Branham [nigbati iṣẹ iranṣẹ mi ṣẹṣẹ bẹrẹ], a o bẹrẹ agbekalẹ kan, a o kọ ijọ nla kan fun ọ nibikan.” Emi ko fẹ gbọngan nla! Ipadabọ Oluwa ni mo n foju sọna fun!

Wọn da ẹgbẹ kan silẹ ti wọn n pe ni “Ojo Àrọ̀-kuro,” wọn lọ si orilẹ ede Kanada ati si ipinlẹ Kalifornia; ṣugbọn wọn ko ṣe aṣeyọri. Nitootọ, ko lee siṣẹ. Ki ni idi? Ohun kanṣoṣo ti wọn mọ .... Wọn jade kuro ninu awọn nkan wọnyi, wọn si ni ìtọ́wò diẹ nipa rẹ. Wọn ni lati ni ohun kan ti wọn yoo ṣe.

Ṣugbọn, arakunrin, ijọ Ọlọrun alaye tootọ ko ni ẹgbẹ, ko ni ẹkọ-adamọ. A n dari rẹ̀ nipa agbara Ọlọrun to wa ninu ọkan ẹnikọọkan. Kọja ni ilu awọn ará rẹ. Maṣe binu si wọn. Awa tobi ju wọn lọ. Maṣe binu si wọn; sa a kọja lọ.

26 Mo fẹ ki ẹ kiyesi eyi pe, ohun nla n ṣẹlẹ nihin. Esau, Moabu, ati awọn ti a tọka si ni aṣalẹ ana. Ọpọlọpọ awọn eniyan yẹn, ọpọlọpọ awọn ti wọn jẹ onigbagbọ ko-gbona-ko-tutu nitootọ. Wọn wa ni ẹnu-aala.

Ah, mo ni lati danu duro fun ohun kan nihin fun iṣẹju diẹ, ko ni gba mi ju iṣẹju kan lọ. Ọpọlọpọ lo n pe ilẹ ileri naa ni Ijọba Ẹgbẹrun ọdun. Ki i ṣe bẹẹ. Ilẹ ileri ni ogun-jija ati iṣeku-pani ninu; Ijọba Ẹgbẹrun ọdun ko ni ni ogun ati ipaniyan ninu. Ẹmi Mimọ lo n duro fun, papa-ogun.

Idanilare, wọn fi ilẹ Egipti silẹ. Ipele mẹta ni irin-ajo wọn. Wọn fi ilẹ Egipti silẹ nipa idanilare, gbigba Ọrọ naa gbọ. Wọn ya ara wọn sọtọ kuro lara awọn ara ilẹ Egipti, wọn si jade. Wọn la Òkun Pupa kọja, wọn si pa awọn nkan naa run lẹyin wọn, eyi duro fun isọnidi-mimọ, nipasẹ ẹjẹ to n pa gbogbo ifẹ ọkan eniyan buburu run - ipele keji irin-ajo naa, ṣugbọn ipele kẹta ni igbati wọn la Jordani ja si Ilẹ Ileri naa nibiti ini wọn wa. Ini wọn ko si ni ilẹ Egipti, bi Ọlọrun tilẹ bukun wọn ni ilẹ Egipti.

27 Ẹyin ọmọ ijọ Luta ti ẹ gbagbọ ninu idanilare, ini yin ko si ninu rẹ, ti a ba pe yin. Ti ẹ ba jẹ ti ijọ Luta lasan, ohun gbogbo ti ẹ o ni niyi.

Ẹyin ti ijọ Mẹtọdisi, ati Nasareni, ati ijọ atipo Mimọ, ati ijọ Ọlọrun, ti ẹ gbagbọ ninu isọnidimimọ, pipa ìwà buburu ti o wa ninu yin run, ipele wíwú gbongbo ẹ̀ṣẹ̀ odikeji odo naa ni ẹ wa.

Ṣugbọn ẹyin ọkunrin ati obinrin, ti ohun kan wa ninu yin, to n ke jade, ibú to n pe ibú, odo Jordani kan wà ti ẹ o la kọja ati ilẹ kan ni odi-keji odo naa.

O wipe, “Ẹ o la aala awọn ará yin kọja. Ẹ o la ààlà awọn ará yin kọja, wọn si sunmọ aala naa. Ti ẹ ba si kọja ni aala wọn, ẹ maṣe sọ ohun kan si wọn. Mo ti fi oke yi fun Esau. Mo ti fi orilẹ ede yi fun Moabu. Nko si fẹ ki ẹ ba wọn ja, ikilọ niyi. Ẹ ṣa a kọja jẹjẹ. Ẹ mọ ibiti ẹ nlọ. Ẹ maṣe kọ iwuwa-si wọn.”

28 Moabu ni wolii eke kan, bisọbu kan ti orukọ rẹ njẹ Balaamu, ẹniti o sọkalẹ wa ti o si wọ agọ awọn eniyan

naa lọ lati mu ki wọn o ṣe agbekalẹ igbalode, ki gbogbo wọn o si parapọ, nitoripe ará ni wọn i ṣe. Ṣugbọn wọn ki i ṣe bẹẹ! Wọn jẹ ibatan, wọn ki i ṣe ojulowo ara!

“Maṣe ṣe atako rẹ; ṣa a maa tẹsiwaju, ẹ fi i silẹ. Ẹ san owo ọja ti ẹ ba ra, ti ẹ ba ni lati la ilu yi kọja.” A yan an tẹlẹ lati ri bẹẹ. Ti Ọlọrun yoo ba ti fẹ, tabi ki O ti ṣe iyantẹlẹ Moabu lati darapọ mọ Israẹli, wọn ko bá ti darapọ. Ti O ba ti ṣe iyantẹlẹ Esau lati lọ pẹlu Israẹli, Esau ko ba ti wọle, ko ba si ti lọ. Ṣugbọn Ọlọrun fun un ni ini tirẹ ni odi-kejii odo naa.

29 Koburu, bawo ni iwọ yoo ṣe gbiyanju lati mu ki gbogbo ijọ Luta ri i, ki gbogbo Baptisti ri i, gbogbo ijọ alagba, ati Nasarẹni, ati awọn Atipo Mimọ? Maṣe da wọn lẹbi. Ohun gbogbo ti wọn mọ niyẹn. Ohun gbogbo ti o wa ninu wọn niyẹn.

Ṣugbọn si ẹyin ti ẹ gbagbọ (Ọlọrun), si ẹyin ti ẹ mọ, si ẹyin ti ẹ ni ohun kan ninu yin to n pe ibú naa! Ti a ba ti kun gbogbo ibu ti o wa ninu yin, nigbana, ẹ duro si ibiti ẹ wa. Ṣugbọn bi o ṣe ti emi ati ile mi, niti emi, ohun kan wa ti o tayọ ohun to n rí! Ilẹ kan mbẹ ni odi-keji odo naa nibikan, ibú kan si wa to ke pe ibú. A ko lee tán oungbẹ mi pẹlu ẹkọ-adamọ. A Ko lee tán oungbẹ mi pẹlu ijọ ti o rẹwa. A ko lee tẹmilọrun pẹlu ipolongo isọji nla. A ko lee tẹmilọrun pẹlu isin imularada. Ohun kan ninu mi, ti o ju eyi lọ, ti o n pè!

30 Nitorina, ẹ fi wọn silẹ. Ẹ maa tẹsiwaju. Ẹ maṣe ṣe ariyanjiyan pẹlu wọn. Ṣugbọn awa n kọja lọ si ilẹ miran. A ko yan wọn lati lọ pẹlu yin. Wọn ko ni lọ pẹlu yin, eniyan meji ha lee rin papọ bikoṣepe wọn rẹ? Ṣugbọn si awọn ti o fẹran Ọlọrun, si awọn ti Ọlọrun pe -

Koburu, wọn lee sọ pe, “Ọlọrun lo fun un ni ijọ yi. Ọlọrun lo ṣe eyi.”

O dara bẹẹ. Ọlọrun sọ pe, “Mo ti fun Esau ni oke yi; ẹ maṣe kọlu u. Ṣugbọn mo ni ohun miran fun yin. Ẹ kọja lọ si odi-keji odo naa!” Amin.

Eyi ni ifẹ ọkan mi, ẹyin ara, lati ri i pe ijọ mi kọja si ilẹ miran, ifẹ ọkan lati de odikeji. Ti ohun kan ba wa ninu rẹ nihin, lakọkọ, to n pe, ohun kan yoo wa lati dahun si ipe naa. Ki o fidi-kalẹ sinu iṣẹ adaran ko to fun ọ, lati wọ inu okowo kan lọ ko to fun ọ, lati darapọ mọ ijọ, ki o si fi orukọ rẹ sinu rẹ ko to fun ọ; nitoripe ohun kan wa to n pe, ni odi-keji lọhun, ni odi-keji, ni isọda odo Jordani, titi ti iwọ yoo fi bọ si ọwọ Ọlọrun loke ọrun. Ibú lo n pe ibú.

31 Joshua mọ pe aṣẹ ti a fifun oun lagbara pupọ. Njẹ ẹ ṣe akiyesi, nigbati Joshua bẹrẹ si lọ si odi-keji Jordani, bi Joshua ti ranti aṣẹ ti a fifun un? “Maṣe jẹki iwe ofin yi [Ọrọ Mi] kuro ni ẹnu rẹ.” Ni ede miran, “Joshua nko bikita ohun towu ki awọn ẹya naa sọ, ohun towu ki alufa yooku sọ, duro ti Ọrọ yi! Nigbana ni iwọ yoo mu ọna rẹ ṣe rere. Iru ohun nla towu ki wọn o ṣe, ati iye ohun kekere ti wọn n ṣe, ati iye ẹgbẹ eniyan yowu ki wọn o gbẹkalẹ, duro ti Ọrọ naa, Joshua! [Ah, akiika!] Duro ti Ọrọ naa. Ọrọ yi ko gbọdọ kuro ni ẹnu rẹ ....” Ẹ jẹki n ka a lẹẹkansii.

Ṣe ara giri, ki o si mu aya rẹ le gidigidi, ki iwọ lee kiyesii lati ṣe gẹgẹ bi ohun ti a kọ sinu ofin naa, eyiti Mose iranṣẹ mi ti palaṣẹ fun yin! Maṣe ya kuro ninu rẹ, si apa-ọtun tabi si apa-osi.

32 Ti Ọrọ naa ba sọ pe ki o ṣe ohun kan, ṣe e! Nko bikita nipa ohun yowu ki ẹgbẹ naa sọ, ṣe e botiwu-kori! Eyi ni Joshua ti Ọlọrun n reti. Maṣe ya kuro ninu rẹ rara. Duro ti Ọrọ naa.

.... Maṣe ya kuro ninu rẹ si ọtun ... tabi si osi, ki iwọ lee mu ọna rẹ ṣe rere.

Ah, ẹ ro pe ẹ n ṣe rere nigbati ẹ ba nkọ awọn gbọngan ile ijọsin nla-nla, ti ẹgbẹẹgbẹrun eniyan n darapọ mọ ijọ yin. Eyi ki i ṣe iṣe rere. Iyẹn ko mu yin sunmọ Ilẹ Ileri rara. Ohun ti a nilo ni Ọlọrun si i, a fikun Ẹmi Mimọ!

... Ki iwọ lee ṣe rere nibikibi ti o ba lọ.

Iwe Ofin yi ko gbọdọ kuro ni ẹnu rẹ; ṣugbọn iwọ o maa ṣe aṣaro ninu rẹ ni ọsan ati oru.

Nigbati iwọ ba n ro lati ṣe ohun kan, njẹ iwọ n tẹle Ọrọ Ọlọrun nipa rẹ? Njẹ iwọ n wa ilepa rẹ ninu Ọrọ naa? Njẹ iwọ n waasu ohun ti ṣe ti Bibeli? Tabi ṣe iwọ da bi ọpọlọpọ loni, ati ọpọlọpọ “to n waasu ẹkọ ilana ati aṣẹ eniyan?”

33 Iwe ofin yi ko gbọdọ kuro ni ọwọ rẹ .... Tabi, ẹnu rẹ.

“Ẹnu rẹ,” ohun ti iwọ n sọ. Ki i ṣe ki o ka a nikan, ki o si kuro ninu rẹ. Sọ ọ! Gbe igbe aye Rẹ! Fi kọ-ni!

.... Ṣugbọn iwọ o maa ṣe aṣaro ninu rẹ ni ọsan ati ni oru, ki iwọ ki o lee kiyesi ati ṣe gẹgẹ bi gbogbo ofin ti a kọ sinu rẹ.

Ṣe ẹ ri ohun ti Joshua ọjọ oni yoo jẹ? Ṣe ẹ ri ohun ti Joshua ti ijọ Ẹmi yoo jẹ? Iru Joshua kannaa ni wọn ni ninu ijọ ti ara. Ijọ ti Ẹmi ni lati jẹ ohun kannaa.

Ti Bibeli ba sọ pe, "Bikoṣepe a tun eniyan bi, oun ko lee ri Ijọba Ọlọrun," Joshua ti Ẹmi yoo sọ pe, "Amin."

Ti Bibeli ba sọ pe, "Jesu Kristi, ọkannaa lana, loni, ati titi laelae," Joshua ti Ẹmi yoo sọ ohun kannaa. O jẹ ọkannaa. Ti Bibeli ba sọ pe, Iwe naa, Ọrọ naa, sọ pe "Ẹ duro ni ilu Jerusalẹmu, titi ti a o fi kun yin pẹlu agbara latoke wa. Lẹyin eyi ni Ẹmi Mimọ yoo ba le yin, nigbana ni ẹyin yoo jẹ ẹlẹri mi," Joshua ti Ẹmi yoo sọ ohun kannaa.

34 Ti Peteru, ni ọjọ Pẹntikọsti ba sọ pe, "Ẹ ronupiwada, ki a si baptisi yin ni orukọ Jesu Kristi fun imukuro ẹ̀ṣẹ̀ yin, ẹ o si gba ẹbun Ẹmi Mimọ," Joshua ti Ẹmi ko ni ya kuro ninu rẹ rara, ṣugbọn yoo sọ ohun ti Ọrọ naa sọ gẹlẹ.

Ti Iwe Marku ori kẹrindinlogun ba sọ pe, "Ẹ lọ si gbogbo aye, ki ẹ si maa waasu ihinrere. Ẹnikẹni ti o ba gbagbọ ti a si baptisi ni a o gbala; ẹnikẹni to ko ba gbagbọ ni a o dalẹbi. Àmì wọnyi ni yoo maa ba awọn ti o gbagbọ lọ; ni orukọ mi ni wọn yoo maa le ẹmi eṣu jade; wọn yoo maa fi ede tuntun sọrọ; wọn yoo fi ọwọ wọn gbe ejò; wọn yoo mu ohun oloro, ki yoo pa wọn lara; ti wọn ba gbe ọwọ wọn le alaisan, ara wọn yoo ya," Joshua ti Ẹmi yoo sọ ohun kannaa. Yoo maa ṣe aṣaro ninu rẹ lọsan ati loru, lati mu ki ọna rẹ ṣe rere.

35 Mo fẹ ki o sakiyesi ohun ti o ṣẹlẹ. Joshua, nigbati o kọkọ de ibi isọji rẹ akọkọ, igba akọkọ ti o ni lati fihan pe oun ni Joshua tootọ .... O yẹki Israẹli ti mọ iyẹn.

Ko si iyemeji, alufa naa ni ero ti o yatọ. Wọn wipe, "Bayi, a o pagọ sihin titi di akoko iruwe ... Tabi titi di igba ooru, Jordani yoo ti lọ silẹ nigbana."

O dabi ẹnipe Ọlọrun fi awọn ohun omugọ siwaju awọn Joshua ti Ẹmi.

O mu un wa sibẹ ni oṣu kẹrin, nigbati ikun-omi Jordani jẹ ilọpo mẹta si mẹrin bi o ti maa n ri. Ọlọrun n dan an wo, lati mọ boya oun ni Joshua tootọ.

Jẹki ohun gbogbo kuna, jẹki gbogbo eniyan miran ṣe rere, jẹki ikuna ṣe rere. Jẹki eniyan ti o ni iwa-bi Ọlọrun, ti o ṣẹ́ agbara Rẹ, ṣe rere, ki o si mu iporuru de ba ọ. Ṣugbọn ti iwọ ba mọ ibiti o n duro le, iwọ yoo duro! Ohun yowu-ki o ṣẹlẹ, ti gbogbo aye ba ja ọ kulẹ, iwọ yoo duro bakannaa. Iwọ ko ni ya kuro ninu Ọrọ Ọlọrun.

36 Jordani naa kun to ilọpọ mẹta si mẹrin bi o ti maa n ri, o n ru, irisi rẹ n bani-lẹru, o kun fun ẹrọfọ. Ṣugbọn Joshua sọ pe, "Ọlọrun sọ pe a o wọ ilẹ ileri naa laarin ọjọ mẹta. A o si lọ!"

Bayi alufa yoo sọ pe, "Bayi, duro fun iṣẹju kan, Joshua. Ọmọwe ni wa. A jẹ ọlọgbọn. Ọpọlọpọ wa nihin lo jẹ onimọ-ẹrọ lati ilẹ Egipti. A mọ bi a ti n ṣe awọn nkan wọnyi, nitorina, a o duro fun igba-diẹ, titi ti odo naa yoo fi lọ silẹ, a o si lee rin laarin rẹ. Ṣe iyẹn ko rọrun pupọ?"

"Nko bikita nipa ohun ti iwọ n ro. Ọlọrun sọ pe laarin ọjọ mẹta, awa yoo de ilẹ naa, a si nlọ! A n wọ ilẹ naa lọ laarin ọjọ mẹta."

Kiyesi ohun ti Joshua ṣe. Ki ni ohun ti o fi siwaju? Ṣe awọn alufa ni? Rara, ṣa. O fi Ọrọ naa siwaju. O wipe, "Ẹ gbe apoti naa! Ki gbogbo ẹyin alufa si kuro nibẹ. Ẹ bọ si ẹyin rẹ. Ẹ maṣe gbiyanju lati dari rẹ, ẹ jẹki o dari yin."

37 Eyi ni iṣoro ti ọjọ oni. A n gbiyanju lati lọ saaju Ọrọ naa, ki a fi silẹ, ki a si mu ki Ọrọ naa ba eyi mu, ati ki Ọrọ naa ba iyẹn mu. Ki Ọlọrun bukun ọkan yin, ohun ti a nilo loni, ni ki a tẹle Ọrọ naa!

Ọrọ lo n dari. Nigbati O de Jordani; Jordani pinya, wọn si kọja. Nibi isọji rẹ akọkọ, o fi ohun akọkọ siwaju. O ni idi fun eyi. O ni idikan, nitoripe Ọlọrun ti fi aṣẹ fun un, Pe, "Duro ti Ọrọ naa. Jẹki Ọrọ ṣe e. Ninu gbogbo ijade wọn, wọn nlọ sinu ogun naa, nitoripe Ọlọrun ti fi aṣẹ fun un, wọn gbe apoti naa siwaju.

Lẹyin ti apoti naa ba ti lọ, ki ni ohun ti o lọ lẹyinnaa? Wọn yoo maa kọrin, awọn to nlo ohun elo orin yoo maa lọ, siwaju ki ija naa to bẹrẹ. Hallelujah!

Ohun ti a nilo loni niyi, ohun ti a ni ni owurọ yi: awọn akọrin, awọn ohun elo orin, a n kọrin, a n yọ. A fi Ọrọ siwaju, a n ka Ọrọ naa. Ija naa yoo si bẹrẹ. O di dandan ki a ṣẹgun, a ni lati ṣẹgun. Ẹ duro ti i, ẹ maa tẹle idari Rẹ, yoo si pa yin mọ ni akoko iṣoro.

38 O ni idi daradara fun un. Ranti eyi pe, nigbati o de odikeji odo naa, siwaju ki o to la odo naa kọja, o ran

awọn amí kan, awọn meji, lati lọ ṣe ayẹwo ilẹ naa. Bayi, Mose ti ran ẹgbẹ kan lọ tẹlẹ, ṣugbọn gbogbo wọn pada wa pẹlu rudu-rudu. Kiyesi iṣẹ iranṣẹ tuntun naa. Oun ko ran ọpọlọpọ eniyan lọ bi ti Mose. O mọ pe nibiti eniyan ẹgbẹrun kan-abọ ba wa, ero ẹgbẹrun-kan abọ ọtọọtọ ni yoo wa nibẹ. Ṣugbọn eniyan meji pere ni o ran lọ. O wipe, "Ẹ lọ sibẹ, ki ẹ sị se amí ilẹ naa."

Bayi, a fẹ wọ inu ohun kan ti nko fẹ ki ẹ padanu rẹ̀. O wipe, "Bayi, nigbati ẹ ba de ilẹ naa ..." Wọn de ilẹ naa, lati bẹ ilẹ naa wo, lati mọ boya ileri naa ri bẹẹ, ki ẹ wo boya bẹẹ ni ... iru ilẹ ti o jẹ, ati bi wọn yoo ṣe wọ inu rẹ. Wọn de ilẹ naa. A ko ṣe akọsilẹ orukọ awọn amí naa. Ṣugbọn nigbati wọn de ilẹ naa, wọn de Jẹriko funrarẹ. Nigbati wọn si de Jẹriko, kilo ṣẹlẹ? Wọn ṣe alabapade panṣaga kan, obinrin ti ko ni orukọ rere.

39 Mo fẹ ṣe akawe kan. Boya ko tọna, ṣugbọn mo fẹ mu koko ọrọ kan jade nipa rẹ. Ko si itan ti a kọ nipa igbesi aye Rahabu. A kan mọ pe panṣaga ni obinrin naa i ṣe. Ẹ jẹki a ro o pe a tọ ọ lati idile otoṣi pupọ, ti o si di eniyan ti ko ni orukọ rere. Ti o si jẹ ọdọbinrin arẹwa. O bọ si oju popo lati ṣe iṣẹ panṣaga ki o lee ṣe itọju iya ati baba rẹ alailagbara; ko si ọna fun un lati siṣẹ, o kan n ta ararẹ jẹun lasan. Ṣugbọn mo lee ro pe o mọ pe ohun ti oun n ṣe ko tọna, ni gbogbo igba to n ṣe e. Ohun kan wa ninu rẹ to n da a lẹbi, Pe "Ko tọna lati maa ṣe eyi." Obinrin naa mọ pe ko dara lati maa ṣe bẹẹ.

Ni ọjọ kan, o gbọ pe Ọlọrun kan wa ti okiki Rẹ n kan. Ọkan rẹ bẹrẹ si wariri. O ri iranṣẹ kan ti a ran lati ọdọ Ọlọrun naa to n mura lati ṣe iṣẹ alagbara nla naa, eyiti o sọ fun un nipa ohun ti yoo ṣẹlẹ. Ki ni ohun ti o sọ? Bayi, Joshua ni awọn àmì ti a fifun un. Joshua ni iru awọn àmì kannaa ti Mose ni, gẹlẹ. Nitorina, nigbati o ... Rahabu ko beere fun àmì Joshua; o kan gbọ nipa rẹ ni.

Afiwe ijọ, o jẹ afiwe ijọ tootọ ti a ti mu lọ sinu panṣaga. Mo jẹ ọmọ ijọ Mẹtọdisi loni, ti ijọ Baptisi lọla, ọmọ ijọ alagba ni ọtunla. "Ijọ ti a ti fi sinu iṣe panṣaga ti ẹmi."

40 Ṣugbọn lojiji, oniwaasu kekere kan wa si inu ilu naa, o si sọ pe, "Ọlọrun kan wa laaye, ti o wa lana, ti ko si yipada titi di oni. Agbara Rẹ ko yipada. O n ṣe iṣẹ kannaa ti O ṣe nigbati O wa lori ilẹ aye nihin." Awọn onișẹ Rẹ mbọ lọna.

Nisisiyi, Rahabu panṣaga, ẹniti aye mọ si panṣaga, o jẹ afiwe iru onigbagbọ kan loni, onigbagbọ tootọ. Ko sọ pe, "Bayi, mo gbọ pe Joshua lee ṣe awọn iṣẹ iyanu, nitoripe oun ni o gba ipo lẹyin Mose. N o fẹ lati ri awọn àmì naa. Ti emi ba si lee ri awọn àmì naa, nigbana ni emi yoo gbagbọ." Koburu, ko ni lati fi awọn àmì naa han dandan, nitoripe obinrin naa gba a gbọ botiwu-kori. Ki i ṣe Tomasi. O gba a gbọ.

41 Bayi, Mose, nigbati o ni awọn àmì naa, o lọ, o si ṣe awọn iṣẹ àmì naa, ṣugbọn ki i ṣe àmì naa lo mu wọn de ilẹ ileri. Oun kọ́. Àmì naa kan jẹ ifidimulẹ iṣẹ ti a ran an ni.

Rahabu si gba a gbọ lai ri ohunkohun! O wipe, "Gbogbo wa ni ẹru n ba."

Abajọ ti Nikodemu sọ pe, "Rabbi, awa mọ pe olukọni lati ọdọ Ọlọrun wa ni Iwọ iṣe: Ko si eniyan ti o lee ṣe awọn nkan wọnyi, bikọṣepe Ọlọrun wa pẹlu rẹ. Gbogbo wa ni a mọ bẹẹ."

Gbogbo aye mọ bẹẹ loni! Billy Graham n fi ipe jade pe, "A ni lati pada si Pentikọsti." Agbarijọ ijọ n pe jade pe, "A ni lati pada si ilana awọn wolii, si iṣe awọn to n fedefọ, si awọn to n sọ itumọ ede, si iwosan latoke wa, si awọn oluwosan ninu awọn ijọ wa, ki a maa gba Ẹmi Ọlọrun laaye lati maa sakoso." Ọlọrun n fi ipe Rẹ jade. Awọn eniyan bẹru iwa bi Ọlọrun tootọ, wọn si n wipe "Ninu ohun gbogbo ... ọkan wa n wariri."

42 Bayi, obinrin yi ko ni lati ri iṣẹ àmì ti Joshua yoo ṣe pẹlu ọwọ rẹ tabi pẹlu ọpa rẹ. O gbagbọ. "Mo gbọ, mo si gbagbọ, ati nisisiyi, emi nbeere fun aanu. [Ah, bi a ṣe lee mu ẹkọ kan jade nihin!] Emi n beere fun aanu fun emi ati ile mi."

Ẹ wo ẹ̀ṣọ́ ile tubu ti ṣe ọmọ ilẹ Romu ni aṣalẹ ọjọsi, eyiti o fa ida ararẹ yọ lati gba ẹmi ararẹ, akọda, ara Filipi. Paulu wi fun un pe, "Maṣe ṣe ararẹ níbi. A wa nihin."

O wipe, "Ki ni emi yoo ṣe lati ni igbala?"

O wipe, "Gba Jesu Kristi Oluwa gbọ loni; a o si gba ọ la, iwọ ati ile rẹ pẹlu."

Eeṣe? "Iwọ ati ile rẹ kẹ̀"? Dajudaju. A o gba ile rẹ la pẹlu rẹ. Eeṣe? Ti o ba ni igbagbọ ti ó tó lati gba ara rẹ la, o lee ni igbagbọ ti o to fun igbala ile rẹ pẹlu. Bẹẹ ni, iwọ ati ile rẹ!

43 Ẹ wo Rahabu. Rahabu wipe, "Saanu fun mi! Da mi si. Nko fẹ ku pẹlu awọn alaigbagbọ wọnyi. Nko fẹ ku bi ẹranko! Mo fẹ ku si abẹ aabo Jehofa. Mo gba Ọlọrun yin gbọ, nitoriti iṣe Ọlọrun ọrun oun aye. O n ṣe awọn nkan ti a n ri. O n sọ nkan di rírí. Nko ti i ri i ki O maa ṣe e ri, ṣugbọn mo gba A gbọ botiwu-kori." Ṣe ẹ rii, ko ti i ri Jehofa ri, o kan gbọ nipa Joshua ni. Ko ti i ri Ọlọrun ri, ko ti i ri eyikeyi ninu iṣẹ Ọlọrun ri; o kan gbọ nipa Rẹ ni. Awọn miran ti ri i, oun si gbagbọ nipa gbigbọ. Bayi, o wipe, "Mo n fẹ ojurere fun ara mi, ati fun baba mi, ati

iya mi. Arugbo ni awọn mejeeji, wọn ko si lee rin mọ. Mo ni awọn ara kan. Mo fẹ ni igbagbọ fun wọn."

Bẹẹ ni awọn amí naa, awọn oniwaasu naa, wipe, "bẹẹ ni, O n bọ ni ọna yi, awa yoo si gba ilẹ naa. Bayi, ti iwọ ba fẹ gba wọn la, kó wọn wá sinu ile rẹ. [Halleluyah!] Ti iwọ ba gba a gbọ, lọ ko wọn wá sihin, nitori awa ko ni jẹbi rẹ, ti wọn ba wa loju popo. Ṣugbọn ti iwọ yoo ba fi wọn pamọ sinu ile rẹ, aabo wọn yoo jẹ ojuṣe wa [hallelujah, ninu eyiti okùn pupa naa yoo maa farahan ni oju fereṣe]. Awa yoo dahun fun ohun to ba ṣẹlẹ si wọn ti iwọ ba fiwọn si inu ile rẹ."

44 Ah, ẹyin ara, ti akoko kan ba wa ti a ni lati fi awọn ololufẹ wa pamọ si inu ile naa, ọjọ oni ni - inu ile igbagbọ. Mu wọn wọle, nitori akoko kan mbọ ti a o mi aye. Baba wa, iya wa ati awọn arabinrin wa nikan ni yoo yọ ninu ile igbagbọ naa, nitori agbara Ọlọrun yoo mi orilẹ ede naa lẹẹkansi. Bẹẹ lo ri. Awọn ara ile igbagbọ nikan si ni a o gbala.

Bayi, o sọ pe, "Emi ko ni daabo bo wọn, bikoṣepe iwọ kó wọn wá sinu ile igbagbọ naa." Obinrin naa si mu wọn bura pe wọn ko ni pa oun tabi idile oun run. O wipe, "Ti iwọ yoo ba mu wọn wọle, a o gba wọn la." O sìn wọn si oju-ọna, wọn si lọ.

45 Panṣaga nla yi, Rahabu, di onigbagbọ. Mo sọrọ lori itan igbesi aye rẹ nihin nigba diẹ sẹyin. Lẹyin ti a ti gba ọrọ rẹ ro, ti a si mu un wa sinu igbagbọ (nitori igbagbọ rẹ ninu Ọlọrun, a mu un wa sinu igbagbọ Israẹli, ẹni aitọ), o fẹ balogun kan ninu ẹgbẹ ọmọ ogun Israẹli. Kiyesi ohun ti Ọlọrun ṣe fun obinrin yẹn. Wọn si ni ... Wọn lọ si Betlẹhẹmu, wọn si bi ọmọkunrin kan. Ọmọkunrin yi, wọn pe orukọ rẹ ni Boasi. Lati inu Boasi yi ... O fẹ Rutu, lati ipasẹ Rutu ati Boasi ni Jesse ti jade wa; lati inu Jesse ni Dafidi ti jade wa; lati inu Dafidi ni Jesu ti jade wa. Hallelujah!

Eeṣe? "Igbagbọ n wa nipa gbigbọ," gbigbọ nipa Ọlọrun kan, eyiti ṣe Ọlọrun ọrun oun aye, ati gbigbagbọ ninu Rẹ. Gbigba ki ni gbọ? Aṣẹ ti Ọlọrun ti fifun eniyan kan ti orukọ rẹ n jẹ Joshua, gbigba aṣẹ naa gbọ.

46 Joshua ni igbagbọ ninu aṣẹ ti a fifun un, bi Mose pẹlu ti ni igbagbọ ninu tirẹ. Ipo nkan buru fun Mose, o dabi ẹnipe ó kuna ni ọpọlọpọ igba, ṣugbọn ó la a ja ni aṣẹgun, ó si ku lori apata naa. Angẹli si gbe ara rẹ lọ.

Ọlọrun, jẹki emi pẹlu lọ bẹẹ. Jẹki n di aṣẹ ti O fifun mi mu titi di ọjọ naa, nigbati n o ṣetan lati ku, n ó si ri apata naa to n duro ti mi.

Joshua n pa aṣẹ ti a fifun un mọ. Bi o tilẹ jẹ pe o ni .... Ọlọrun yoo ṣe e ni mimọ, nitoripe o duro ti Ọrọ naa.

Bayi, Rahabu mọ pe Joshua ni aṣẹ yi. Bayi, maṣe padanu eyi. Di awọn nkan wọnyi mu ṣinṣin ninu ọkan rẹ. Joshua ni aṣẹ naa. Rahabu da a mọ ki o to ri ohunkohun. O mọ pe Joshua ni agbara Ọlọrun ti yoo fi gba ilẹ naa. O beere fun aanu. Ọlọrun saanu fun un. Bayi, nigbati Joshua wa si ilẹ naa, lootọ, a mọ pe, ẹru baa.

47 lẹyinnaa, asẹ nla miran ti Joshua ni ni lati pin ilẹ naa pẹlu awọn eniyan naa.

Bayi, ranti, Pe, "iwe ofin naa ko gbọdọ kuro ni ẹnu rẹ." Bẹẹni ó ni Ọrọ Ọlọrun. "Bi Emi ti wa pẹlu Mose, maa lọ. Bi mo ti wa pẹlu Mose, bẹẹ ni Emi yoo wa pẹlu Rẹ. Emi ki yoo ja ọ kulẹ. Iwọ lee jami kulẹ, ṣugbọn Emi ki yoo ja ọ kulẹ. Ṣugbọn ti iwọ ba ja Mi kulẹ, ore-ọfẹ Mi yoo to fun ọ, n o fa ọ dide pada. Sa a maa tẹsiwaju. Niwọn igbati iwọ ba duro ti Ọrọ Mi, Emi yoo ṣe itọju yin."

48 Bayi o ni lati pin ilẹ naa, awọn ẹya mejila ni yoo si pin ilẹ naa fun. Bayi, ti o ba ni awọn ohun kan ati omiiran ti o jẹ ikogun nkọ? Ti o ba fẹran ẹya Gad ju bi o ti fẹran ẹya ti Efraimu lọ nkọ, ti o si fẹran ẹya Josẹfu ju bi o ti fẹran ti Judah lọ nkọ? Ṣugbọn ko ṣe e bẹẹ. O pin ilẹ naa nibamu pẹlu Ọrọ Ọlọrun, bi Ẹmi ti fihan an. O pin in nibamu pẹlu ẹya. Ki ẹ kiyesii pẹlu pe, o ṣe e nipa ifihan naa, nipa imẹmi-yatọ. Nipasẹ imẹmi-yatọ nipa Ẹmi Ọlọrun, ni o ṣe e.

Ikọọkan awọn ìyá ti iṣe Heberu, to n bi awọn ọmọ ọwọ wọnyẹn, wọn n fun wọn ni orukọ. Orukọ kọọkan si ni itumọ.

Jakọbu, nigbati a bi i, bi o ti jẹ ibeji, iya rẹ pe e ni "ajinilẹsẹ," Jakọbu. Ṣugbọn nigbati o gba agbara iṣẹgun, ti o si jija-kadi pẹlu angẹli, Ọlọrun yi orukọ rẹ pada kuro ni Jakọbu si Israẹli, "ọmọ ọba alade."

Orukọ ti eniyan n jẹ ni nkan ṣe pẹlu igbe aye rẹ. Nigbati Peteru, ẹniti i ṣe pẹja-pẹja, o ti ṣẹgun nipa igbagbọ rẹ ninu Jesu, Jesu wipe, "Orukọ rẹ ni Simoni; sugbọn Emi yoo pe ọ ni Peteru, eyiti i ṣe apata kekere," O n yi o pada. Orukọ rẹ ni ohun kan lati ṣe pẹlu rẹ, ati nipa ipo ti iwọ yoo ti ba ararẹ lori ilẹ aye.

49 Nigbati iṣẹlẹ nla yi ṣẹlẹ, nigbati ikọọkan awọn ìyá Heberu yi, ni ipo irọbí wọn ke jade, bi i "Reubẹni," eyiti o fi i si ipo ... Palẹstini, gẹlẹ bi iya ti sọ, ti o si pe orukọ rẹ, o sọ ọ jade. Nko ni akọsilẹ gbogbo rẹ nihin, ṣugbọn Reubẹn tumọsi "oluṣọ agutan," Gad tumọsi "Ọlọsin ẹran," Efraimu si tumọsi "ọlọgbin agbado."

Bayi, Joshua nipa imẹmi-yatọ ti ẹmi, adari tuntun naa, nipasẹ imẹmi-yatọ, o fi ẹnikọọkan si ibiti o yẹki o wa, o pin in ilẹ naa gẹlẹ bi o ti yẹ.

50 Afiwe to rẹwa fun ọjọ oni, niti ohun ti a nilo Joshua kan fun loni. Iṣoro ti a ni loni nipe nigbati a de ilẹ ileri wa, Gad fẹ maa ṣe ọsin agutan bi ti Efraimu, ọkan fẹ maa ṣe ohun ti ikeji n ṣe. Ẹnikọọkan fẹ ri bakannaa. Jẹki Ọlọrun fun ẹnikan ni ẹbun iwosan, gbogbo eniyan ni yoo maa beere fun ẹbun iwosan. Efraimu, Gad ati gbogbo awọn yooku fẹ ṣe àdàlù, ki wọn o si di ọkan. Ṣugbọn a jẹ oniruru ninu ipo wa. Ki i ṣe gbogbo wa ni a ni ẹbun ọgbọn, ki i ṣe gbogbo wa ni a lee sọ asọtẹlẹ, ki i ṣe gbogbo wa ni a n fedefọ, gbogbo wa kọ ni wolii. Ṣugbọn Ọlọrun ti fi awọn kan sinu ijọ ti wọn n sọtẹlẹ, awọn kan n fedefọ. Ṣe ẹ ri bi rudurudu naa ti ri. Nigbana, ẹ ko lee de ibì kankan. Eeṣe, awọn ọmọ ogun Filistini yoo bori wọn kiakia. O daju. Ṣugbọn nigbati ẹnikọọkan, nipa adari kan, ti a ba pín wọn nipa imẹmi-yatọ tị emi, ti o si fi wọn sinu ara naa, nibẹ ni wọn wa, ti wọn si di adùn aye! Ọlọrun, fun wa ni Joshua kan. Ọlọrun, mu Joshua kan tọ wa wa pada, eyiti yoo di aṣẹ naa mu pẹlu Ọrọ rẹ.

Idi niyi ti Ọlọrun fi sọ fun un, pe, “Iwe ofin yi ko gbọdọ kuro ni ẹnu rẹ, ki iwọ maa ṣe aṣaro ninu Rẹ lọsan ati loru,” nitoripe o ni aṣẹ kan ti a gbe ka iwaju rẹ.

51 Nisisiyi, iru adari wo ni Joshua dà, ko padanu ogun kan ri, bikoṣepe ohun kan ṣe ilodi ninu ijọ. Nigbati Akani jí ere kan, ki i ṣe irisi Joshua .... Tabi igbagbọ ni o ṣe e. O jẹ ... O jí aṣọ ara Babiloni kan ati ère wura kan kuro ninu agọ; nigbati o si ṣe bẹẹ, o ṣe idena si iṣẹgun wọn.

Nigbati ará kan ba n jiya, gbogbo ará lo n jiya. Ohun ti Ọlọrun n bọ wa lati fi lelẹ ni ọjọ kan, arakunrin, ni ijọ ti ko ni abawọn tabi eeri. O n bọ lati ṣe ifi-lọlẹ ijọ ti a kun fun Ẹmi Rẹ, eyiti ifẹ Ọlọrun latoke wa so ọkan wọn papọ, ti wọn yoo rin ni isọkan.

52 A gbọdọ ṣẹgun gbogbo rudurudu wọnyi. Ṣe ijọ Mẹtọdisi lo tọna, ṣe ijọ Baptisti lo tọna, ṣe ijọ alagba ni, ṣe ti awọn onigbagbọ to n fi ifedefọ ṣe ijẹri Ẹmi Mimọ ni, ṣe ti Nasarẹni ni, tabi ti awọn Atipo Mimọ? Awọn ijọ ẹlẹyamẹya ti o din diẹ ni ẹgbẹrun kan lo wa, yatọ si awọn Buddi ati oniruru yooku. Nibo ni a wa? Ohun kan lodi. Ère kan wa ti a fipamọ sibikan ninu agọ. Joshua ṣẹ́ gègé.

Ẹ jẹki n sọ eyi ni owurọ yi, bi ti Elijah ni Oke Karmẹli, “Bi Ọlọrun ba jẹ Ọlọrun, jẹki O dahun bi Ọlọrun.” Ti ijọ Baptisti ba tọna, jẹki wọn o ṣe afihan àmì Jesu Kristi. Ti awọn ara ijọ Nasarẹni ba tọna, jẹki a ri wọn pẹlu àmì naa ti wọn n fihan, ki o maa ṣe ohun ti O ṣe nigbati O wa nihin. Afedefọ ba tọna, jẹki a ri wọn ki wọn ṣe ohun ti O ṣe. Nigbana ni a o mọ.

53 Awọn ọmọ ẹyin Joshua sọ pe, “A o tẹle ọ niwọn igba ti a ba ri Ọlọrun to n ba ọ rin bi O ti ba Mose rin.”

O yẹki awọn ọmọ ẹhin Jesu sọ ohun kannaa: “A o ba ọ rin nigbati a ba ri awọn àmì Jesu Kristi to n siṣẹ pẹlu rẹ. A o ṣe bẹẹ.” Ohun ti o yẹki a ṣe niyi, ohun ti o yẹki ijọ sọ niyi. Eyi ni iha ti o yẹki ijọ Kristẹni kọ. Nigbana ni ẹ lee mu awọn ẹbun ẹmi, iṣẹ àmì, ati awọn osiṣe si ipo ti o yẹ. Ti ẹnikan ba jẹ oluwosan latọrun wa, iyẹn ko ni ohun kan i ṣe pẹlu ẹniti o ni ẹbun ifedefọ. Ẹnito n fedefọ ko ni ohun kan i ṣe pẹlu ẹnito n sọtẹlẹ. Ṣe ẹ rii, a ni oriṣiriṣi ipele iṣẹ iranṣẹ yi.

54 Nisisiyi, nigbati Ọlọrun fi aṣẹ ìpe mi fun mi .... Mo ti n duro lori eyi fun idi yi kanṣoṣo. “Ẹbun ati ipe Oluwa wa laisi ironupiwada.” Ko si eniyan ti o lee mu ara rẹ jẹ nkan. Ọlọrun lo mu ọ jẹ ohun ti o jẹ, nipa ore ọfẹ Rẹ. A ko ni ọna ti a fi lee mu ara wa jẹ ohun kan. Jesu wipe, “Tani, o lee fi igbunwọ kan kun ọjọ aye rẹ nipasẹ aniyan siṣe?” Talo lee mu ara rẹ tobi sii tabi kere sii nipasẹ aniyan siṣe? Iwọ ko lee ṣe e.

Nigbati Ọlọrun fi aṣẹ ipe mi fun mi, mo ṣe awawi lori rẹ. Mo wipe, “Emi ko ni amuyẹ ti o to .... Nko ni imọ iwe. Nko lee ṣe awọn nkan wọnyi.”

Ọpọlọpọ ninu ẹyin ti ẹ wa ninu apejọpọ ni owurọ yi, ẹ si n gbe nihin titi di oni… Nigbati O farahan nibi odo naa lọhun, ni aworan ọwọn ina, ti O si duro sibẹ, ti O sọrọ jade, ti O sọ pe, “Bi a ti ran Johanu Onitẹbọmi siwaju wiwa Kristi lakọkọ, bẹẹni iṣẹ iranṣẹ rẹ yoo ṣaaju wiwa Rẹ lẹẹkeji.”

55 Ẹ wo ohun ti O ti ṣe. Imọlẹ to farahan nibẹ, iwe iroyin ṣe akọsilẹ rẹ, okiki iṣẹlẹ naa lọ yika gbogbo orilẹ ede Amẹrika ati si awọn orilẹ ede miran.

Dokita Lee Vayle wa ni orilẹ ede Canada ni akoko naa. O ranti igbati O farahan ninu iwe iroyin ilẹ Canada naa, mo gbagbọ pe bẹẹni. Ṣe bẹẹ kọ, Lee Vayle? Ninu iwe iroyin orilẹ ede Canada naa, mo gbagbọ pe bẹẹni. Wọn pe akọle rẹ ni “Imọlẹ abami farahan lori iranṣẹ Ọlọrun agbegbe kan, nigbati o n ṣe iribọmi fun awọn eniyan.”

Ọpọlọpọ awọn eniyan sọ pe, “Irori lasan ni.”

Ṣugbọn ni ọjọ kan, Ọlọrun pinnu lati pa ẹnu awọn alaigbagbọ mọ, nitoriti O n duro ti Ọrọ Ọlọrun. Ọwọn

ina kannaa ti o dari awọn ọmọ Israẹli, O jẹ ọkan naa loni, O n dari ijọ ti ẹmi - O si jẹ ọkan naa to dari ijọ ti ara. O farahan lẹẹkansi, wọn si ya aworan Rẹ niwaju awọn alatako, ati niwaju awọn awòye. Oun ni a fi kọ yi, otitọ ti ko lee kuna, O n ṣe iṣẹ kannaa, O n dari awọn eniyan kan nipa ti Ẹmi gẹgẹ bi O ti dari awọn ọmọ Israẹli nipa ti ara lọjọsi, O n duro ti Ọrọ naa.

Bayi, ẹ sọ pe, “Ki ni aṣẹ naa ti a fifun ọ?” Bayi, ranti pe, Ọlọrun ko ni kuro ninu aṣẹ ti O fifun eniyan.

56 N o fẹ lati ṣalaye rẹ fun yin, tabi ni ọna kan. A o sọ ọ bayi nihin. Ibiyi ni àmì kekere kan wa, oun ni aṣẹ ipe naa; bayi agbelebu kekere kan n duro si kọrọ kan ati Bibeli ni ikeji, ṣugbọn akọle naa wa laarin nihin. Iyẹn ni aṣẹ naa.

Mo pè yin nija niwaju Ọlọrun, ati awọn angẹli ayanfẹ rẹ, ati Jesu Kristi. Aṣẹ naa nipe, “gbadura fun awọn alaisan.” Ibeere naa nipe, “nko ni amuyẹ ti o to lati ṣe e?”

“Fun idi eyi ni a bi ọ, idi ti ibi rẹ ati igbe aye rẹ ṣe jẹ ajeji niyi, pe o ni lati gbadura fun awọn alaisan. Ti iwọ yoo ba lee mu wọn gba a gbọ, ki o si jẹ olootọ nigbati o ba gbadura, ki yoo si ohun kan ti yoo lee duro niwaju adura rẹ, ati jẹjẹrẹ paapa.” Eniyan melo lo ti ka eyi, ni gbogbo ọdun yi wa? O lọ kaakiri gbogbo agbaye.

57 Bayi, nisisiyi mo sọ pe, “Nko lee ṣe e, nitoripe nko ni agbara lati ṣe e. Wọn ko ni gba mi gbọ - emi jẹ otoṣi, nko ni imọ iwe.” Awọn aroye ti mo n ṣe niyi.

O wipe, “Bi a ti fi àmì meji fun Mose lati ṣe ifidimulẹ aṣẹ ti a fifun un, bẹẹ ni [ki i ṣe pe 'iwọ yoo']… a fun ọ ni àmì meji. Ọkan yoo jẹ nipa ọwọ rẹ. Ikeji nipe iwọ yoo mọ aṣiri ikọkọ ọkàn awọn eniyan, ero inu wọn. Nipa eyi ni wọn yoo gbagbọ, nipasẹ awọn àmì meji wọnyi.” Bayi ranti. Fetisilẹ. Maṣe kuna lati mọ eyi. Àmì naa kọ ni isẹ ti O ran mi! Àmì naa kan n tọka si aṣẹ naa ni.

Ti o ba jade lọ si oju popo, ti o si ri àmì kan, ti o sọ pe, “Ibusọ marun ni o ṣẹku lati de ilu Jeffersonville,” iyẹn kii ṣe ilu Jeffersonville. O jẹ àmì lati fihan ọ pe iwọ wa ni oju ọna ti o tọ.

58 Ti Mose, nigbati o lọ si ilẹ Egipti ...? O ni àmì kan, pẹlu ọpa kan ni ọwọ rẹ ati pẹlu ọwọ rẹ. Àmì naa nihin ki i ṣe aṣẹ naa, ko ju ohun ti o jẹ si Mose lọ. Ti gbogbo ọmọ Israẹli ba sọ pe, “Gbogbo ẹyin ọmọ Egipti, ati gbogbo ẹyin ọmọ Israẹli, ẹ wa sihin. A ni ọkunrin kan ti o lee pidan pẹlu ọwọ rẹ. O yẹki ẹ ri i. A ni ọkunrin kan nihin ti o lee mu ọpa, ki o si sọ ọ di ejo. Ẹ wa wo o?” Iyẹn kan jẹ atọka lasan ni. Iyẹn kọ ni aṣẹ naa. Wọn ko maa duro fun àmì-atọka lasan. (Ki Ọlọrun ran wa lọwọ.) Wọn n reti idande kan!

Bẹẹni aye oṣi yi, aye ti o ti di arọ yi n foju-sọna fun idande kan, o si n wo àmì-atọka kan. Ọlọrun ṣaanu fun wa! Àmì naa ki i ṣe ohun miran bikoṣe àmì to n ṣe afihan aṣẹ naa. Iṣẹ iranṣẹ tuntun naa niyi. Oluwa ṣẹṣẹ fihan mi ni. Pe, “Gbadura fun awọn alaisan. Mu ki awọn eniyan naa gba ọ gbọ.” Ọlọrun ko fi eyi silẹ. Aṣẹ Rẹ ni, ohun to wu ki o ṣẹlẹ, botiwu ki n kuna to. Mo ti kuna gidi. Ko yẹki n tẹsiwaju pẹlu awọn àmì wọyẹn; iyẹn ki i ṣe ifẹ Ọlọrun, ṣugbọn Ọlọrun ti bukun un botiwu-kori. Ṣugbọn mo ti ṣetan lati fi oke yi silẹ. Mo fẹ lọ si odikeji Jordani. Mo fẹ mu aṣẹ naa lọ sibẹ. “Mu ki awọn eniyan naa gba ọ gbọ.”

Mo wipe, “Wọn ko ni gba mi gbọ.”

“A o fi àmì meji miran kun un.”

59 Bayi, iṣoro ti o wa nibẹ nipe a ti wo àmì naa lati igba yi wa.

“Ah, Arakunrin Branham, gbe ọwọ rẹ lee.”

“Ah, o yẹki o ri ohun to ṣẹlẹ. Duro si iwaju rẹ nigbati àmì-ororo naa ba wa lori rẹ, yoo sọ ohun gbogbo ti o wa lọkan rẹ fun ọ.” Otitọ ni eyi.

Mo lọ si ile-iwosan nihin ni ọjọsi. Nibẹ ni awọn dokita naa wa, wọn ko lee ri ohun to n ṣe obinrin naa. Nigbati awọn dokita naa jade kuro ninu iyara naa, obinrin naa pada lọ, o si n duro si ayika ibusun. “Wọn wipe awọn ko lee ri ohun to ṣe lodi ninu agọ ara mi.” O wipe, “Arakunrin Branham, o lee sọ fun mi!”

Mo wipe, “Ti iwọ yoo ba gba mi gbọ, mo lee ṣe bẹẹ.”

Obinrin naa sọ pe, “Mo gbagbọ.”

Ẹmi Mimọ si sọ pe, “Eyi ati iyẹn. Ohun ti o jẹ niyi, gẹlẹ. Wo o, ti eyi kii bạ se bẹẹ.” Ọmọ ijọ Junie Cash ni.

60 Obinrin miran nibẹ sọ pe, “Ẹyin mi n yọmi-lẹnu,” O wipe, “awọn dokita ko lee ri ohun to faa.”

Mo wipe, “Njẹ iwọ gba mi gbọ gẹgẹ bi wolii rẹ?”

O wipe, “Mo gbagbọ.”

Mo wipe, “Kilo ṣẹlẹ, si ọ ni ibẹrẹ oṣu kẹfa .... Wọn n gbiyanju lati siṣẹ le ọ lori, wọn si n gbiyanju lati ṣe iṣẹ abẹ si ọpa ẹyin rẹ. Ki i ṣe ohun to n ṣe ọ niyẹn. Iṣan ara kan lo n fa inira. O ṣẹlẹ si ọ nipasẹ ẹru gbigbe, nigbati iwọ n siṣẹ fun ile iṣẹ Ọjà Mc Spaddin.

O wipe, “Mo ranti igbati o ṣẹlẹ! Mo ranti nisisiyi.”

Iyẹn kọ lo mu un larada. Iyẹn kan tọka eniyan si aṣẹ naa ni. Ẹ dẹ́kun sisimile àmì-atọka naa; ẹ jẹki a wọ ilu naa lọ! Ẹ jẹki a fi ori oke yi silẹ; ẹ jẹki a lọ si ilu naa. Ẹ jẹki a sọdá a Jordani!

61 Mo ti kuna. Mo ti ṣe lodi. Idi niyi ti mo fi ti gbe iwaasu yi kalẹ bi mo ti ṣe yi. Nitoripe, O wipe, “Bi Mo ti wa pẹlu Mose, bẹẹ ni Emi yoo wa pẹlu rẹ,” nigbati ọwọ yẹn si ti sọkalẹ wa, ti o si tọka si Iwe Mimọ kannaa .... fun igba-pipẹ, mo ti kuna nitoripe nko mọ ohun ti aṣẹ naa jẹ. Mo ti n wa ohun kan ti o ta-yọ ẹda. Ọlọrun ko lee kuro ninu aṣẹ Rẹ. Ọlọrun lo fi aṣẹ naa fun mi, O si gbọdọ wa bẹẹ titi.

Ṣugbọn gbogbo awọn onigbagbọ to n fi ifedefọ ṣe ijẹri Ẹmi Mimọ fẹran lati maa ri àmì. Wọn maa n fẹ lati ri i. Bibeli wipe, “Iran buburu ati panṣaga n wa àmì.” Ṣugbọn aṣẹ naa nipe “gbadura fun awọn alaisan.” Ọkẹ aimọye igba ni mo si ti kuna lati gbadura fun awọn alaisan, nitoripe gbogbo won n fẹ àmì. Gbogbo wọn lo fẹẹ.

62 Ni ọjọsi, mo n gbiyanju lati siṣẹ iranṣẹ naa, mo wọ inu gbọngan lọ. Ẹnikan si wa si ori pẹpẹ, o wipe, “Bayi, Arakunrin Branham, duro fun iṣẹju kan. Iṣoro ti emi yatọ. Mo ṣẹṣẹ mọ ohun kan ni.”

Mo wipe, “Koburu, dokita lee ṣe ayẹwo rẹ.”

Ah, nko fẹ iyẹn. Mo fẹ mọ nisisiyi. Iṣoro ti emi yatọ pupọ.“

Mo wipe, “Koburu, mo korira lati maa ṣe eyi, arakunrin.” Mo wọ inu rẹ lọ, ohun akọkọ ti iwọ yoo mọ, nipe, Ẹmi Mimọ ....

O wipe, “Yin Oluwa! Bẹẹ ni!”

Mo wipe, “Ki ẹyin yooku wa nisisiyi, ẹ jẹki n gbadura fun yin.”

Nigbati mo ṣe bẹẹ, njẹ ẹ mọ ohun ti ẹnikeji sọ? “Ọrọ ti emi pẹlu ṣe pataki bi tirẹ.” Mo si gbadura fun eniyan mẹfa si mẹjọ pere, ipade naa si wa si opin; eyi maa n mu ki o rẹ mi bi igbati mo fẹ ku.

Mo ti maa n ro o pe, eeṣe ti iyẹn maa n mu ki o rẹ mi bẹẹ? Idi ni pe mo n ṣe e ni ọna ti o lodi. Àmì to n tọka si aṣẹ naa ni eyi jẹ. Ki i ṣe aṣẹ naa. A ti fi àmì naa han kaakiri gbogbo aye. Ati si oniruru ede - Ilẹ Adulawọ, India, Asia, Europe, kaakiri agbaye - laarin ẹgbẹẹgbẹrun ati ọkẹ-aimọye eniyan, wọn mọ nipa àmì-atọka naa. Mo ti ṣetan lati fi oke yi silẹ. Mo fẹ bọ si odikeji Jordani. Mo fẹ bọ sinu ohun kan ni ipele giga, nibiti igbagbọ mi yoo ti ga de ipele kan nibiti awọn eniyan yoo ti maa gba imularada nigbati mo ba gbadura fun wọn.

63 Kiyesii. Ọlọrun ti fi si àrọ́wọ́tó awọn eniyan: “A bi ọ; lati gbadura fun awọn alaisan. Ti iwọ ba lee mu ki wọn o gba ọ gbọ ...”

Mo wipe, “Wọn ko ni gbagbọ.”

O wipe, “Emi yoo fun ọ ni àmì meji, nipa eyiti wọn yoo gbagbọ.” Kiyesii nigbana pe, àmì wọnyi, wọn ti fi igbagbọ wọn sinu wọn; si awọn àmì-atọka naa, dipo aṣẹ naa, nipa gbigbagbọ pe “a ran ọ lati gbadura fun wọn.”

Bayi, nigbati awọn eniyan ba wa si ori ila fun adura, ni kete ti wọn ba ti de ipele yẹn .... ko si ohun ti mo lee ṣe nipa rẹ, ti wọn ko ba ti i de ipele igbagbọ naa. Nigbati wọn ba si de ibẹ, nigbana ni n o sọ pe, “Mo fun ọ ...”

64 Hattie Wright, mo ro pe o wa nihin ni owurọ yi. O n joko si ọhun yẹn. Oun ni eniyan akọkọ ti a lo ẹbun naa fun nigbati a ri awọn ọkẹrẹ naa. O si mọ aṣẹ naa nipa eyi. Ati nigbati Ọlọrun ṣe ẹda ohun kan nigba meje ọtọọtọ. Mo wipe, “O jẹ Ọlọrun kannaa ti O lee ṣẹda kan agbo fun Abrahamu, lati fi idi aṣẹ ipe rẹ mulẹ; Ọlọrun kannaa ti O lee sẹda ọkẹrẹ, nitoripe o jẹ ohun ti mo nilo.”

Hattie Wright naa lọhun (to n joko si ẹhin gbọngan), pẹlu ọkan rẹ ti ko si ninu ohun ti aye, o n gbagbọ. O wipe, “Arakunrin Branham, ọrọ ti o sọ jẹ otitọ nikanṣoṣo!” Ko sọ lati ẹnu rẹ; Ọlọrun lo sọrọ lati inu ọkan rẹ.

Mo wipe, “Hattie, beere ohun ti o fẹ. Emi yoo si fifun ọ.”

O wipe, “Ki ni ki emi beere?”

Mo wipe, “Iwọ ni baba arugbo ati iya arugbo kan to n joko sihin. Iwọ ni arabinrin ti o jẹ arọ. [O si n joko sinu aga arọ naa.] O lee beere fun iwosan rẹ. O lee beere fun iya rẹ, baba rẹ. Otoṣi ni iwọ, iwọ ko ni owo lọwọ. Beere ohun ti o ba fẹ.”

O wipe, “Koburu, nko mọ ohun ti o yẹki n beere.” Pe,“Nko mọ.” O wipe, “Ifẹ ọkan mi ti o ga ju ni igbala ọkan awọn ọmọkunrin mi mejeeji.”

Mo wipe, “Mo fi awọn ọmọkunrin rẹ fun ọ, ni orukọ Jesu Kristi.” Awọn mejeeji si gba iyipada ọkan, wọn n fẹran Jesu Oluwa, awọn mejeeji ni a ti ṣe iribọmi fun ni orukọ Rẹ, wọn si n sin Ọlọrun lojoojumọ pẹlu gbogbo ọkan wọn.

65 Ed Daulton, to n joko nibikan nihin (ninu apejọpọ), nipa awọn ọmọ rẹ, ohun kannaa.

Mo ti ri, o kere tan, ninu ipade kan, eniyan bi ẹgbẹrin tabi ẹẹdẹgbẹrun, boya ẹgbẹrun kan, awọn eniyan n kọja niwaju pẹpẹ ninu ipade kan, ni ẹyọ kọọkan. Ohun akọkọ ti iwọ yoo mọ, n o lọ, n o si gbadura fun wọn. Dajudaju, ara wọn n ya. Ọmọbinrin kekere kan wa, eyiti aisan jẹjẹrẹ inu ẹ̀jẹ̀ n pa a ku lọ. Dajudaju mo mọ ohun ti o lodi pẹlu ọmọ naa, nko sọ ọrọ kan si eyikeyi ninu wọn. Ṣugbọn nigbati ọmọde yẹn de ibẹ̀, mo wipe, “Olufẹ, mo fun ọ ni ifẹ ọkan rẹ. Iwọ ni aisan jẹjẹrẹ inu ẹjẹ, mo si fun ọ ni imularada rẹ ni orukọ Jesu Oluwa.” Mo kọju si apejọpọ, mo wipe, “mo pe eyikeyi ninu yin nihin nija, ẹ mu ọmọdebinrin yẹn lọ si ọdọ dokita, ki ẹ si se ayẹwo rẹ, ki ẹ si wo o ti o ba ni aisan jẹjẹrẹ inu ẹjẹ naa ninu rẹ mọ botiwu-kori.” Eeṣe? Ọmọbinrin naa ti gbọ. Bi ti Rahabu panṣaga, o gba a gbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ. Nigbana ni Ọlọrun nipasẹ Ẹmi Rẹ, O wa, O si wipe, “Obinrin naa niyi.” Ọgọọgọrun ti kọja niwaju pẹpẹ lai gba ohunkohun bi mo ti mọ to. Mo kan n gbadura ni.

66 Pada si ọdọ awọn eniyan, “Ti iwọ yoo ba gbagbọ.” A ti fi aṣẹ naa fun mi. Eyi ni ojulowo. A ti fi àmì-atọka naa han. Bayi ti iwọ ba gba iyẹn gbọ, ti iwọ yoo ba gbagbọ pe Ọlọrun ran mi wa si orilẹ aye lati gbadura fun awọn alaisan, n o lee gba adura igbagbọ fun ọ. Ọna kanṣoṣo ti o lee gba ṣẹlẹ niyi.

Ọlọrun ko lee kuro ninu aṣẹ Rẹ. Emi ti ja A kulẹ. Mo ti wa nihin fun ọdun mẹrinla ti mo n ṣe imẹmi-yatọ nikanṣoṣo, kaakiri gbogbo agbaye, to bẹẹ gẹẹ, ni ẹgbẹẹgbẹrun igba, ninu imẹmi-yatọ ti o to miliọnu kan, mo ro bẹẹ. Mo bi yin ni ibeere yi, njẹ o ti kuna ri? Rara, ṣa. Ti àmì-atọka naa ko ba lee kuna, melomelo ni aṣẹ naa ko lee kuna! Ti àmì naa - eyi jẹ ohun kekere - ti àmì to n tọka si ilu, ko ba kuna lati sọ fun ọ pe ilu naa wa nibẹ, melomelo ni ilu naa yoo wa nibẹ nigbati o ba de bẹẹ! Aṣẹ naa niyi.

67 Bayi, iṣẹ iranṣẹ mi ti n yipada. O ti yipada. Imẹmi-yatọ yoo si maa wa. Wọn yoo si maa wa bi mo bạ se n ni imọlara pe Ọlọrun n fẹ ki n sọ wọn. Ṣugbọn titi di igbana, n o maa gbadura, n o si maa gbe ọwọ le awọn alaisan, bi O ti sọ fun mi lati ṣe, n o si maa tẹle aṣẹ naa. Mo ti duro fun igba pipẹ fun eyi, ṣugbọn mo gbagbọ bayi pe a ti ṣetan lati gba ilẹ ileri naa. Bi o ti daju pe yoo wa, awọn Rahabu wa ti yoo maa duro, ẹnikan yoo wa ti yoo gbaagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ.

Njẹ ẹ lee loye eyi? Gbogbo eniyan ti o ba loye ọrọ naa daradara, ẹ na ọwọ yin soke. Eniyan melo lo mọ pe ọrọ naa ba Iwe Mimọ mu patapata? Ohun ti O sọ niyi. Eyi ni aṣẹ naa; awọn wọnyi jẹ àmì-atọka to n tọka si aṣẹ naa.

68 Bayi, mo pe ẹnikẹni nija lati sọ fun mi, nibikibi ni agbaye ti ẹ ti n gbọ ohun yi, ibikibi ti awọn ohun naa le lọ, fi akoko kan han mi ti O kuna lati sọ ni ori pẹpẹ, tabi ti O ṣe afihan ohun kan ninu iran tabi ohun kan, ti ọrọ ti O sọ ko si jẹ otitọ, ti ko si wa si imuṣẹ gẹgẹ bi O ti sọ. O sọ fun gbogbo eniyan, ohun ti iṣoro wọn jẹ gẹlẹ, ati ohun gbogbo nipa rẹ, ati ibiti wọn ti wa, ati ohun gbogbo nipa ohun ti wọn gbọdọ ṣe. Nigba-gbogbo ti O ba sọ pe, “bayi ni Oluwa wi” si ohunkohun ti o jẹmọ iwosan, o n ṣẹlẹ bẹẹ gẹlẹ. Ti iwọ ba mọ ọ̀kan ti o kuna, jẹki n mọ nipa rẹ. N o feti si ohun naa, n o si mọ. Ko ti i kuna ri, ni gbogbo ọdun mejeejila yi, tabi ọdun mẹrinla. Ko ti i kuna ri, nitoripe ko lee kuna. Ọlọrun lo mu àmì naa wa. Ko lee kuna.

Ki Ọlọrun to fun mi ni àmì naa, O ti fi aṣẹ naa fun mi, ki àmì kan to wa ti yoo maa tọka si aṣẹ kan. Siwaju ki àmì kan to wa ti yoo ma tọka si ilu kan, ilu kan gbọdọ kọkọ wa ti yoo tọka sii. Ti iwọ ba ti gba a gbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ, iwọ yoo gba a. “Adura igbagbọ yoo mu alaisan larada, Ọlọrun yoo si gbe wọn dide.”

69 Bayi, emi funrami ti simile àmì-atọka naa pupọju. “Oluwa, fi han mi nipa eyi ki n to gbadura fun wọn, nitoripe nko mọ ohun ti o yẹki n ṣe.” Lilo àmì naa ko dara rara. Mo torọ aforiji lọwọ awọn eniyan. Awọn apejọpọ ni agbaye, to n feti si ohun yi, ẹ dariji mi! Mo kuna. Ko yẹki n maa ṣe e bẹẹ. Iyẹn ki i ṣe ohun ti O palaṣẹ fun mi lakọkọ. Àmì to n tọka si aṣẹ naa niyi. O yẹki n ti maa gbadura fun awọn alaisan, nibi-gbogbo.

Bayi, ṣe ẹ rii, o ti pada si arọwọto awọn eniyan - ti ẹ ba lee gbagbọ pe Ọlọrun palaṣẹ fun mi lati ṣe eyi. Ohun niyi ninu Ọrọ naa, o jẹ ohun kannaa gẹlẹ pẹlu Ọrọ Ọlọrun, aṣẹ naa.

70 N o fi ika mi ya aworan naa nihin, abala obiripo kan, oṣumare kan. Iyẹn ni majẹmu ti Ọlọrun ba eniyan da. O da majẹmu kan pẹlu iran eniyan pe Oun ko ni pa aye rẹ mọ pẹlu omi. O da majẹmu kan pẹlu ikọọkan awọn apọsteli. O da majẹmu kan pẹlu wolii naa.

Bẹẹ ni ni ọjọ kan ... Ni nkan bi ọdun mẹrinla si mẹdogun sẹyin ni ọdun 1937, ni ọjọ keje Oṣu karun, ọdun 1937, mo ro pe bẹẹni, ti Ọlọrun ba mi da majẹmu kan, pe, "A bi ọ si aye yi lati gbadura fun awọn alaisan - ti iwọ ba lee mu ki wọn o gba ọ gbọ." "Ọkan mi ti n wa fun awọn eniyan naa." Ti iwọ yoo ba mu ki awọn eniyan naa gba ọ gbọ, ki o si jẹ olootọ nigbati o ba n gbadura fun wọn, ko si ohun ti yoo lee duro niwaju adura rẹ."

Mo sọ eyi pẹlu otitọ ọkan ati pẹlu itiju. Ti ẹnikẹni ba wa ti o yẹki o gbagbọ, emi ni ẹni naa - lati ri ohun ti O ti ṣe, ibiti O ti mu mi wa, inu ọgbun ti O ti fa mi jade wa; lati ri ohun ti O ti ṣe ni aye mi, ṣe ẹ rii, nigbati mo ba duro ti mo si sọ ohun kan, Ọlọrun maa n sọkalẹ lati ti i lẹyin, pe otitọ ni.

71 Ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin, ti mo sọ fun yin pe angẹli kan wa, ti o tọ mi wa ninu igbo nigbati mo jẹ ọmọ ọdun mẹta, imọlẹ kan, iji-yika ninu igbo, O si sọ fun mi pe ki n ma mun-siga, muti, tabi ohun miran, pe iṣẹ kan wa fun mi lati ṣe nigbati mo ba dagba. Ẹ ni ẹtọ lati ṣiyemeji eyi. Ẹ ko ni ẹtọ, ṣugbọn o ṣeeṣe ki ẹ ti ṣiyemeji si eyi.

Nibi odo naa, nigbati Ọlọrun sọkalẹ ti O si fi ara Rẹ han lati jẹ iyẹn, nibiti a n duro si .... Ọpọlọpọ ẹyin ti ẹ n joko sihin ni owurọ yi ni ẹ n duro sibẹ. Ọpọlọpọ yin ni ẹ mọ eyi lati jẹ otitọ.

Ọpọlọpọ yin ni ẹ ranti nigbana, nigbati a fi aṣẹ naa fun mi, ti O si wipe, "Lọ, iṣẹ iranṣẹ rẹ yoo lọ si ibi gbogbo ni agbaye, isọji yoo bẹrẹ." Isọji ti ko ti i ṣẹlẹ ri si wa. Isọji naa si tẹsiwaju, kaakiri agbaye bayi, awọn ipolongo isọji iwosan nigbogbo agbaye.

72 Ati emi, lati ọdọ ẹnikan, ẹniti ko jẹ nkan. Nko sọ eyi lati tabuku iya mi to n joko sinu apejọpọ, tabi si baba mi ti o ti lọ, ẹniti a waasu isinku rẹ ni ori pẹpẹ yi. A bi mi, a tọ mi dagba lati inu ẹbi ti o buru jai. Ẹ mọ eyi. Ko si ẹniti o jẹ Kristẹni ninu wa. Ọmuti ni baba mi. Ọlọrun yan ọmọ ọmuti, O si wẹ̀ mi ninu ẹjẹ Rẹ. Ti mo ba lọ si igboro nigbakan lati ba eniyan sọrọ ti mo si n ba ọkunrin kan sọrọ, ti ko ba si ẹlomiran nibẹ ni yoo ba mi sọrọ. Ni kete ti ẹlomiran ba de, ẹnikẹni, ẹniti o wu ki o wa sibẹ, wọn yoo kọ ẹyin si mi nitoripe ọmọ ọmuti ni mi. Bẹẹ ni ọpọlọpọ ẹyin eniyan ninu ijọ mi nihin mọ pe otitọ ni eyi. Mo ni orukọ bi .... Bi ẹranko tabi ohun kan. Nigbakan, a tilẹ sọ pe - ni ilu, si ẹniti o ba wa si ile wa - pe, "Ṣe iwọ yoo darapọ mọ ẹbi oniranu bi eyi?" Ah, ṣugbọn, Ọlọrun, ki ni ohun ti mo ni lati fi ṣogo bikoṣe ẹjẹ Jesu Kristi! Nko ni imọ iwe. Nko jẹ nkankan. Nko ni ohunkohun.

73 Mo sọ fun iyawo mi nigba diẹ sẹyin, pe, "Ro ohun ti o jẹ nigbati ko si ẹniti o lee ba mi sọrọ, mo si fẹran awọn eniyan, wọn ko si ni feti si mi."

Mo ranti iwe kan ti mo n ka, nigbati mo nlọ si ile iwe ... Mo ran awọn ọmọ mi lọ si ile iwe ni ọjọsi, mo si lee ra iwe ati awọn ohun elo miran fun wọn, bi mo ṣe jẹ ọlọpẹ to. N o lọ si ile iwe laisi bata ni ẹsẹ mi, pẹlu irun ti o ti kun bo ọrun mi, ko si aṣọ, mo n wọ aṣọ kootu kan ti o ti gbo laisi awọtẹlẹ, nko tilẹ ni pẹnsu tabi iwe ti n o fi kẹkọ ni ile iwe. Mo ni lati lo pẹnsu ikunju, iwe ajakọ lati fi kọ awọn iṣẹ ti olukọ kọ si oju patako tabi ohun kan. Ko si ohunkohun. O lodi.

74 Mo ranti ohun ti mo n ka ninu iwe kan ni ọjọ kan nibiti Abrahamu Lincoln ti sọkalẹ ninu ọkọ oju-omi lọhun, mo gbagbọ, pe ni ilu New Orleans. Nibẹ ni o ti ri awọn ọmọ ajeji kan to n duro ni papa-oko, pẹlu ẹsẹ wọn nibiti maalu ti sun si ni gbogbo oru, emi si ni bata, gbogbo ọmọ Ọlọrun ni o ni bata."

Nigbati o sọkalẹ ninu ọkọ oju-omi naa, o wo ẹnikan to n duru ni ibujẹ akọ-maalu, ẹni naa si jẹ ọkunrin alawọ dudu kan ti irisi rẹ tobi, o si dara, iyawo rẹ kekere n gbe ọmọ ọwọ kan lọwọ, ọmọ naa n sọkun. Wọn n ta ọkunrin naa, lati maa fi gùn pẹlu obinrin ti o tobi, ki o lee bi awọn ẹru ti o tobi.

Lincoln di ọwọ rẹ le koko, o si fi ẹ̀ṣẹ́ rẹ̀ lu ara wọn. O wipe, "Eyi ko tọna!" Pe, "Ni ọjọ kan, n o dojukọ eyi, bi o tilẹ na mi ni ẹmi mi!" O na an ni ẹmi rẹ, ṣugbọn o dojukọ ọ, o si pa a!

75 Mo wipe, "Ọti mimu yi, igbe aye buburu yi, ko tọna! Ni Ọjọ kan n o kọlu u!" Bawo ni n o ṣe kọlu u. Ṣe pẹlu iru orukọ ti mo n jẹ ni? Ko si ẹniti yoo ba mi sọrọ. Iditi mo fi n saroye pẹlu aṣẹ ti a fifun mi niyi. Ko si ẹniti o bikita fun mi. Ko si ẹnikan nibikibi, laarin awọn eniyan mi nihin.

Nipa ore-ọfẹ Ọlọrun, mo ni lati fi ile mi silẹ, nko tilẹ lee duro sibẹ, nitori awọn eniyan to n pe mi kaakiri agbaye. Awọn oniruru eniyan, awọn ọlọla, awọn alaṣẹ, awọn ọba, awọn eniyan nla, awọn oniṣowo, awọn iransẹ Ọlọrun, lati ibi gbogbo ni agbaye, wọn n pe mi. Wọn n pe, wọn n pe, wọn n̄ pe ni ọjọ si ọjọ, oru si oru. Ki ni ohun ti o ṣe eyi? Ẹjẹ Jesu to n fọ ọkan mi. Bi ẹjẹ Abraham Lincoln ti mu ẹ̀wọ̀n ẹru kuro ni iha ọkunrinn alawọ dudu kan, bẹẹ ni ẹjẹ Jesu Kristi mu ẹwọn ẹ̀ṣẹ̀ kuro ni aye mi, o si mu mi kuro ninu orukọ kan ti o kere si ti ẹranko, o si fi mi sinu orukọ kan, bi ọmọ ore-ọfẹ Rẹ.

76 Mo si ti ṣetan lati lọ si Jordani ni owurọ yi. Mo ṣetan lati duro lori aṣẹ ti a fifun mi. Mo ti fẹran awọn eniyan. Mo ti ṣe itọju wọn. O ti ba mi pade, O fi orișirișì iran han mi, eyiti nko ni akoko lati sọ (ṣe ẹ mọ, a kọ ọ si ẹyin iwe yi), pe, "Iwọ n bikita pupọ ju fun awọn eniyan. Lati ba Mi rin, iwọ yoo da rin ni. Iwọ n fiyesi awọn àmì naa pupọ ju."

Nko mọ ohun ti iyoku jẹ, ṣugbọn wakati naa ti de. Wakati naa ti de nigbati mo ri ọwọ naa ti o walẹ si Iwe Joshua, ti O wipe, "Bi Mo ti wa pẹlu Mose. Bẹẹni Emi yoo wa pẹlu rẹ." Mo gba a gbọ ni owurọ yi. Lati isisiyi lọ, lati oni lọ, n o sin Ọlọrun ninu aṣẹ ti Ó fifun mi. Boya Ó fẹ fi àmì han mi tabi Ó fẹ fi iran han mi, O lee fi wọn han si mi. Ti ko bạ se bẹẹ, nko ni duro siwaju awọn eniyan mọ, ki n si jẹki igbagbọ wọn fa aṣẹ jade lara mi. N o gbadura fun awọn alaisan, n o si fiwọn le Ọlọrun lọwọ, n o si jẹki wọn o lọ. Ti wọn ba gbagbọ ninu aṣẹ naa, Ọlọrun jẹ olootọ sibẹ. O ti mu mi de ihin. Bi O ti ṣe si Mose, bi O ti ṣe si Joshua, O ti ṣe bakanna.

77 Adura irẹlẹ mi nipe, "Ọlọrun, dariji mi. Jẹki n dide, ki n si gbiyanju lẹẹkansii. Ranmilọwọ, Oluwa, Jẹki n dari awọn eniyan wọnyi, ki n si fi wọn sinu Ọrọ naa, titi a o fi lee lọ si Jordani, ki a si lọ si ilẹ ileri naa, nibiti ijọ irapada Ọlọrun nla naa yoo ti gbala lati ma dẹṣẹ mọ." Eyi ni ẹbẹ ọkan mi ni owurọ yi. Gba a gbọ, ki o si ye! Gba a gbọ, ki a si wo ọ san! Mo ba yin sọrọ ni orukọ Oluwa. Ẹ jẹki a gbadura.

78 Oluwa Ọlọrun, ẹlẹda ọrun oun aye, ẹlẹda iye ainipẹkun, ati Olúfúnni ni ohun gbogbo to dara, jẹki aanu Rẹ ati ore ọfẹ Rẹ wa lori iranṣẹ Rẹ lakọkọ, Oluwa. Mo ti ṣe lodi ni oju Rẹ nipasẹ aṣilo ohun atoke wa, nitoripe awọn eniyan n fa a jade lara mi, Oluwa. Mo gbadura si Ọ, Oluwa Ọlọrun, lati wakati yi lọ, ba mi wi, Oluwa, pẹlu Ẹmi Rẹ. Mo gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan mi. Ran aigbagbọ mi lọwọ Oluwa.

Nigbati awọn ọkunrin ati obinrin ba si n wa fun adura, eyiti n o ṣe niwọn igbati iwọ ba fun mi ni èémí ati iye. Jẹki wọn o gbagbọ nisisiyi, bi a ti n gbadura fun wọn, Baba. Jẹki aṣẹ ti Iwọ ti fifun mi yi, jẹki n lee mu un lọ si gbogbo aye. Nigbati mo ba si de ibikibi, nibiti a ti kan àmì-atọka naa mọlẹ, jẹki wọn o mọ pe iyẹn kan n tọka si aṣẹ ni. Jẹki wọn o ni igbagbọ.

79 Oluwa, emi ki yoo duro fun àmì kan mọ tabi ohun kan, lati sọ ohun kan fun mi, tabi boya alaisan kan yoo gba imularada. N o tọ ọta naa lọ pẹlu igbagbọ ni ọkan mi. N o dojukọ ọ nipa ẹjẹ Jesu Kristi. Nipasẹ ẹjẹ Kristi, ko ni lee duro.

Bayi, ti gbogbo nkan wọnyi ba tọna, eyiti a ti fihan pe otitọ ni, bẹẹni ki Iwọ mu alaisan larada, nigbati mo ba gbadura fun wọn, Oluwa, Ọrọ Rẹ ni. Ileri Rẹ ni. Eyi ni mo fẹ lati ṣe. Ran aigbagbọ mi lọwọ Oluwa.

Dari ẹ̀ṣẹ̀ mi ji mi, Oluwa, niti aigbọran si aṣẹ Rẹ. Nko mọ ohun ti n o tun ṣe; ti mo bạ se e Oluwa, a ko ti fihan mi, ko ti i di mimọ si mi. Ohun niyi, nisisiyi. Mo mọ ibiti mo n duro le. Mo mọ aṣẹ ti a fifun mi. Nko ni jẹki Ọrọ yi kuro ni ẹnu mi, lọsan tabi loru. Mo ti maa n duro ti i nigba-gbogbo, Oluwa, - mo sọ fun awọn eniyan pe n o ṣiyemeji ohunkohun ti kii ba ṣe Ọrọ Ọlọrun. Ṣugbọn nko ni waasu rẹ tabi ki n ṣe ohunkohun nipa rẹ, bikoṣe pe o jẹ Ọrọ Ọrọ naa.

80 Ṣugbọn, Oluwa, o ti ṣu mi lati maa wa lojukan. Bi mo ti sọ ni aṣalẹ ana, ogoji ọdun ni aginju, siwa-sẹhin, siwa-sẹhin. Ibukun Ọlọrun, bẹẹ ni. Wọn n sin ẹran, wọn n bi ọmọ, ati ohunkohun miran, ati agbo aguntan ati maalu, ati ohun gbogbo. Ọlọrun, o bukun wọn. Ṣugbọn ni ọjọ kan, O sọ pe, "Ẹ ti pẹ to ni ori oke yi. Ah, ẹ lọ si iha ariwa, si iha Jordani."

Ọlọrun, mo n bẹrẹ ni owurọ yi. Mo n fi àmì atọka yi silẹ nitoripe o n tọka si ilẹ ti o dara. Mo lee kọsẹ. Mo lee lọ si ọna awọn ara Amalẹki, mo lee lọ si iha awọn Hitti ati ti awọn ara Kenani, mo lee kọja ni iha awọn alatako mi. Oluwa, n o ṣaa maa tẹsiwaju nitoripe mo mọ pe ilẹ kan wa nibikan loke. Ibikan wa, ipo kan, ibiti a lee de, nibiti Iwọ yoo ti dahun adura, nibiti a o ti gba ohunkohun ti a ba beere fun, ki i ṣe jẹjẹrẹ paapa ni yoo duro iwaju adura naa. Mo mọ eyi lati jẹ otitọ. Eyiti mo gbagbọ ti mo si n duro fun, Oluwa. Mo si fi ara mi le Ọ lọwọ ni owurọ yi fun isin Rẹ, ni orukọ Jesu Kristi. Amin.

81 Sa a ti gbagbọ, ṣaa ti gbagbọ,

Ohun gbogbo lo ṣe e ṣe, sa a ti gbagbọ;

Ṣaa ti gbagbọ, ṣa a ti gbagbọ,

Ohun gbogbo lo ṣe e ṣe, ṣa a ti gbagbọ.

Bayi, a ti pa ẹrọ ohùn naa, nitoripe eyi yoo lọ si gbogbo agbaye. Eyi wa lati inu ọkan mi. Ṣe ẹ lee loye eyi, ijọ?

Ọlọrun ko lee sọ ohunkohun, ki O si ko Ọrọ Rẹ jẹ. Ọrọ Rẹ ko lee kuna. Awọn ileri Rẹ jẹ otitọ. O ti n duro de akoko yi lati igba yi wa. Ṣe ẹ rii, adura igbagbọ lo n mu alaisan larada, ki i ṣe àmì. Adura igbagbọ! "Ti ẹ ba lee gbagbọ," Jesu wipe, "Mo lee ṣe e. Mo lee ṣe e, ti iwọ ba gbagbọ." Bayi, ti Ọlọrun ba ti fun mi ni agbara lati

gba adura igbagbọ fun yin, ti O si ti ṣe ileri rẹ, ti O ti fi idi rẹ mulẹ pe otitọ ni, bayi njẹ ẹ gbagbọ? Ohun ti mo beere, mo ri i gba, ti iwọ ba gba a gbọ. "Ti iwọ ba lee mu ki awọn eniyan gba ọ gbọ, ti o si jẹ olootọ nigbati o ba gbadura, ko si ohun ti yoo lee duro niwaju adura rẹ."

82 Arakunrin, arabinrin, ti mo ba fẹ jẹ olootọ, akoko yi ni mo gbọdọ jẹ olootọ. Lẹyin gbogbo asiṣe mi, lati fihan, ohun ti mo fẹ .... Idi ti mo fi ti mu awọn iwaasu yi wa tẹlẹ, pe Ọlọrun fihan pe alaanu ni Ọlọrun. Mosẹ se awọn asiṣe tirẹ, eniyan nla bi tirẹ. Nigbati Joshua wa, oun pẹlu n ṣe asiṣe tirẹ. Ṣugbọn Ọlọrun sọ pe, "Bi mo ti wa pẹlu Mose, bẹẹ ni Emi yoo wa pẹlu rẹ."

Bayi, ẹ wo Ọlọrun, ni ọdun meji sẹyin, O n fi Iwe Mimọ yi han mi, "Bi mo ti wa pẹlu Mose, bẹẹ ni Emi yoo wa pẹlu rẹ. Emi ki yoo wo asiṣe rẹ." O mọ pe wakati yi mbọ. Wakati naa si ti de bayi. Ṣe ẹ rii, o pada wa lẹẹkansii, nitoripe Ọlọrun ko lee kuro ninu rẹ laelae.

"Nipa igbagbọ ni a gba yin la." Eniyan melo lo mọ eyi? Iye eniyan daradara towu ki o gbadura fun yin, iye oniwaasu daradara to wu ki o waasu fun yin, o ni lati ni igbagbọ tirẹ fun igbala. Ṣe bẹeni? Igbagbọ tirẹ ni .... Nko bikita iye iwaasu daradara ti o ti gbọ, iye ijọ daradara ti o darapọ mọ, igbagbọ tirẹ lo n gba ọ la. Botiwu ki o ké to, botiwu ki o bẹbẹ to, botiwu ki o sọkun to, botiwu ki o jo to ninu Ẹmi, igbagbọ rẹ lo n gba ọ la. Ṣe bẹẹ ni? Ọna kanṣoṣo ti a o fi wo ọ san niyi.

83 Ti Ọlọrun ba fi iṣẹ kan ran eniyan kan, oniwaasu kan, ti oniwaasu kan n waasu igbala, ti o si jẹ iṣẹ kan, ti o si ri pe otitọ ni iwaasu naa, ti Ọlọrun fi idi rẹ mulẹ nipa Ọrọ Rẹ, pe otitọ ni; bawo ni o ṣe yẹki o gbagbọ ninu ẹbun iwosan kan, nigbati a ba ti fi idi rẹ mulẹ nipa Ọrọ naa ati nipa angẹli kan, pẹlu àmì meji to n tọka si ailekuna mejeeji? Bawo ni o ṣe yẹki o gbagbọ! Ṣe ẹ rii ....

Lati ṣe afihan rẹ pe ki i ṣe ifẹ Ọlọrun pipe gẹlẹ lati ṣe bẹẹ, àmì naa pẹlu maa n mu ki o rẹ mi. Eniyan melo lo mọ eyi? Ẹ bi iyawo mi to n joko sẹyin leere. O lee sọ fun yin. Ẹniti - o ṣoro fun un ju gbogbo eniyan yooku lọ - o ni lati farada a pẹlu mi. Iwọ ko ni mọ ibiti o wa, iwọ yoo maa rin kiri, ati eyi, iyẹn, iwọ yoo lọ si igboro diẹ, iwọ yoo rin lọ si oju popo fun igba diẹ, iwọ yoo si duro.

84 Bayi, bi mo ti n bọ lati ibi awọn ipade ti a ṣe. Mo gbadura fun awọn ti o wa lori ila. Lakọkọ, a ṣe isin awọn aṣalẹ kan lai pe fun adura, lai pin kaadi adura jade. Isọji kan si wa, ninu eyiti a o ti pin kaadi adura jade. N o duro nigbamiran, n o sị se imẹmi-yatọ bi aadọta si marun din laadọrin, boya ogoji tabi aadọta, lẹẹkannaa; ni aṣalẹ kọọkan. Ṣe bẹẹ ni, Gene, Leo, ati ẹyin ti ẹ wa nihin, ti ẹ wa ninu ipade naa? Dajudaju, otitọ ni. Ki ni ohun ti eyi ṣe? Nigbati o ba fi mi silẹ, ti mo si n bọ wa sile, n o gbagbe ibiti mo wa, n o fẹ mọ ibiti mo ti wá si oju-ọna masọsẹ.

Bayi, ṣe ẹ fẹ sọ fun mi pe Ọlọrun lo n ṣe eyi si eniyan? Rara, ṣa. Eniyan lo n ṣe eyi si ararẹ, nipa titẹle àmì-atọka, dipo aṣẹ ipe gangan. Mo duro si abẹ igi kan lọhun, ni ẹba ọna naa, nibikan ni Washington, tabi nibikan lọhun. Mo wipe, "Oluwa, ti iwọ yoo ba jẹki n pada sinu ara mi, ki ara mi le pada, jẹki n mọ otitọ, ki n lee tọ awọn eniyan lọ tarata, ki n si tẹle aṣẹ naa bi o ti tọ."

85 Mo ti mọ bayi. Bi mo ṣe n joko sihin ni ẹba oke ni Kentucky ni ọjọsi, ni nkan bi afẹmọju ni owurọ ọjọ kan, O fihan mi. Ohun niyi. Ohun niyi. Bayi mo lọ ni orukọ Oluwa wa Jesu. Ohun niyi.

Ẹ gba a gbọ, ki ẹ si ye! Ẹ gba a gbọ, ki ẹ si gba imularada! Nko lee mu ki ẹnikẹni gba a gbọ. Iwọ funrarẹ ni yoo gba a gbọ. Ṣugbọn mo ti sọ otitọ fun yin. Ọlọrun ti jẹri si pe otitọ ni nipa Ọrọ Rẹ, nipaṣẹ angẹli Rẹ, nipaṣẹ iṣẹ àmì ati iṣẹ iyanu, fun ọdun mejila gbako. Ti wọn ko ba ni gba a gbọ bayi, wọn ko ni gba a gbọ laelae. Ṣe bẹẹ ni? Ṣugbọn wakati naa ti de, nibiti o ti su mi lati maa duro si ori oke yi. Mo fẹ lọ si Jordani. Mo fẹ wọ inu ileri kikun naa lọ. Mo fẹ ni igbagbọ ninu ara mi, ki i ṣe ki n maa wo àmì, ki i ṣe ki n maa wo ohun kan ti Ọlọrun ti fi han tabi iru àmì-atọka kan. Mo fẹ maa wo Kafari, ki n si maa sọ pe, "Nipa igbagbọ, mo wa, Oluwa Ọlọrun. Mo n bọ wa ni orukọ Jesu Oluwa."

86 Bayi awọn kan wa nihin ti a o gbadura fun ni owurọ yi. Mo n bọ wa lati dojukọ awọn aisan ati awọn inira ti o wa ninu agọ yin ni orukọ Jesu Kristi. N o ṣe bẹẹ titi ti Ọlọrun yoo fi gba ẹmi mi. Niwọn igbati O fun mi ni ọgbọn ati oye, n o wa lati gbadura. Maṣe kuna ninu ohun ti o gbagbọ pe nigbati mo ba gbadura fun yin, ara yin yoo ya. Ẹ ni eyi ninu ọkan yin. Ti ẹ ko ba gba a gbọ, nigbana, ẹ maṣe wa rara, nitori ẹ o pa ara yin lara.

Bayi, si ẹyin ti ẹ n feti si ohun naa, o si wa nihin. Lati isisiyi lọ, ko si imẹmiyatọ mọ titi ti Ọlọrun yoo fi ... Sọ fun mi lati ṣe ohun kan, n o lọ lati ṣe e.

Ṣugbọn niwọn igbati mo ba n duro si ori pẹpẹ, ti mo n sọ pe, "Bayi wo mi. Ṣe o gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ. Bẹẹ ni, eyi ni eyi ati iyẹn. Iwọ ni John Doe, o wa lati ibi bayi-bayi. Iwọ ti ni aisan jẹjẹrẹ fun igba pipẹ. Dokita Lagbaja ati tamẹdo sọ fun ọ pe ararẹ ko ni ya. Iwọ lọ ṣe ohun kan. Bayi o nilati da iyẹn pada, ki o sị se atunṣe eyi, ki o sị se eyi ki ara rẹ to ya. O dara, Arakunrin Doe, lọ bayi, gba a gbọ." "Nisisiyi, iwọ ni Arabinrin Lagbaja ati tamẹdo, o wa lati ibi bayi-bayi." Iwọ wa lati ibi bayi-bayi." Lẹyinnaa n o wọ ipo ti nko ti ni mọ ohun

ti n o ṣe mọ. Ohun akọkọ ti iwọ yoo mọ, ẹlomiran yoo wa, n o maa fi oju wa ẹniti mo n wo kiri. N o si jade kuro nibi ipade naa, ati "Ibiti mo wa?' Ko si iyẹn mọ.

87 Mo n tọ yin wa ni orukọ Jesu Oluwa, bi iranṣẹ Rẹ. Ti Ọlọrun ko ba ti i fihan ọ ni akoko yi, pe otitọ ni mo ti sọ fun yin, nigbana, ẹ ko ni gbagbọ pe mo ti sọ otitọ fun yin. Amin. O dara, otitọ ni. Eniyan melo lo n fẹ ki a gbadura fun awọn, ẹ na ọwọ yin soke. O dara.

Bayi, mo nilo Teddy, Ṣe Teddy si wa ninu gbọngan? [Ẹnikan sọ pe, "Rara, o ni lati lọ."] O ni lati lọ. Tani atẹduru nihin ti o lee tẹ iru orin naa jade "Ṣa a ti Gbagbọ" fun mi? Ti iwọ yoo ba ṣe bẹẹ, ti ẹnikan ba wa nihin ti o lee tẹ-duru? Ṣe o ti ri i .... Tabi, ṣe ẹ ti ka a silẹ, ṣe ẹ ti ṣe bẹẹ, nibikan? Ti ẹnikan ba wa nihin ti o fẹ tẹ-duru fun wa, "Ṣa a ti gbagbọ," atẹduru kan wa siwaju. Boya ọkunrin tabi obinrin, ko ni itumọ, inu wa yoo dun lati ri ọ. O dara, bayi nigbati o n tẹ ẹ jẹjẹ, ti iwọ yoo ba ṣe bẹẹ, arabinrin mi ọwọn.

88 Bayi a ko ni pin kaadi adura jade. Nigbati a ba wa ninu ipade kekere bi eyi, a ko nilo rẹ. Nigbati a ba wa ninu ipade nla, a o si ni lati pin kaadi adura jade, ti mo ba fẹ gbadura fun eniyan bi ẹẹdẹgbẹta. A o si ni lati ṣe bẹẹ, nitoripe ọpọlọpọ eniyan lo wa ninu ... Ninu akojọpọ, ṣe ẹ rii.

Eniyan melo lo gbagbọ pe ifẹ Ọlọrun niyi? Ah, ohun kan mu ki n ni imọlara pe mo ti ṣe ohun ti o tọ .... Ajaga naa kuro ni aya mi. O ti wa bẹẹ fun ọdun mejila, ti mo n mọ pe ohun kan ko tọna, Arakunrin Lee. Bayi, mo mọ pe ajaga naa ti fi ọkan mi silẹ. Mo ti sọ ọ, ati ka a silẹ, o si ti fi àyà mi silẹ bayi.

89 Ranti pe, igbagbọ rẹ ni o lee gba ọ la. Igbagbọ rẹ ni o lee wo ọ san. Njẹ iwọ gba eyi gbọ lati jẹ ohun ti Bibeli sọ? Ọrọ Ọlọrun? Njẹ iwọ gba pasitọ rẹ gbọ lati jẹ iranṣẹ Ọlọrun, iru ijọ ti o wu ki o maa lọ? Ti iwọ ko ba gba a gbọ, fi ijọ rẹ silẹ. Lọ si ijọ ẹniti o mọ pe iranṣẹ Ọlọrun ni. Ti o ba si gbaagbọ, gbagbọ pe otitọ lo n ba ọ sọ, ki o si gba a. Igbagbọ adani rẹ ninu Kristi lo gba ọ la. Botiwu ki pasitọ rẹ dara to, botiwu ki o jẹ eniyan Ọlọrun to, botiwu ki iya rẹ jẹ eniyan mimọ to, botiwu ki Ọrọ Ọlọrun jẹ̀ otitọ to, botiwu ki o sọkun to, botiwu ki o gbadura to, igbagbọ rẹ lo n gba ọ la! Nipa igbagbọ ni a gba yin la.

Ohun kannaa lo n ṣẹlẹ nisisiyi. Botiwu ki .... Ọrọ Ọlọrun sọ pe Oun yoo ran eyi wa nigba ikẹhin. Iwaasu meji ni a gbọ nisisiyi, mo ti ṣe afiwe Israẹli ti ara ati ti ẹmi papọ. A n reti Joshua ti ọjọ oni, eyitiṣe Ẹmi Mimọ, lati dari wa de ilẹ naa. O ni lati sọrọ nipasẹ eniyan kan, nitoripe Ẹmi ni. Mo ti sọ ohun ti Oun ti sọ fun mi fun yin. Bayi, ẹ gbagbọ, ki a si mu yin larada.

90 Bayi, jẹki awọn ti o wa ni apa ila yi, Doc, lọ sibẹ. Billy Paul, nibo ni Billy wa? Wa sihin lati ranmilọwọ Doc, ti iwọ yoo bą se bẹẹ.

Nisisiyi, ẹnikọọkan ẹyin ti ẹ n bọ wa si ori ila adura, ẹ ranti eyi pe, yoo pada si ara yin ti ẹ ko ba gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan yin. Otitọ ni. Ẹ gbọdọ gba a gbọ. Bayi, ẹ ranti, Ọlọrun ṣe afihan rẹ nipasẹ angẹli Rẹ, bayi o gbọdọ gba a gbọ.

Bayi, ẹyin ti ẹ n fẹ ki a gbadura fun yin, ohun ti Bibeli sọ niyi, "Ti wọn ba gbe ọwọ le alaisan, ara wọn yoo ya." Otitọ niyi. A si fẹ gba eyi gbọ, pẹlu gbogbo ọkan wa bayi pe Ọlọrun yoo mu yin larada.

91 Bayi, ẹ gba ọna yi wa, lati ibiyi, ati lati ẹyin; ẹ fi iha yi silẹ, ki awọn to wa ni iha yi, wa ni ọna kannaa. Jẹki awọn ti o wa ni iha iyẹn, duro si apa ọtun, nihin. O dara. Ki ni ẹ sọ? [Ẹnikan ba Arakunrin Branham sọro] N o lọ sibẹ. Bẹẹni, ṣa, nisalẹ nihin lati gbadura fun wọn.

Bayi awọn lẹta ati aṣọ inuju wọnyi, mo ti gbadura le wọn lori. Ọpọlọpọ yin, awọn kan ninu yin, boya ẹni lati lọ. Ẹ maṣe gbagbe laṣalẹ yi, bayi, isin naa wa lori ifidi-mulẹ kan, ifidi-mulẹ atoke wa ti i ṣe ti ijọ tootọ, ṣe ẹ rii?

92 Bayi, si ẹyin ti ẹ n fẹ ki a gbadura fun yin, njẹ ẹ gbagbọ lootọ pe ẹ o gba imularada? Ti ẹ ko ba gbagbọ, ẹ maṣe wa. Ti ẹ ba gbagbọ, ojuṣe yin ni lati wa.

Bayi, emi ki i ṣe oluwosan, ṣugbọn mo ni ẹbun iwosan. Eyiti a ṣe ijẹri rẹ. A ti fihan pe otitọ ni. Ṣe ẹ rii, nigba-pipẹ sẹyin, mo ranti pe mo maa n lọ si ile iwosan ni agbegbe yi. Mo si jẹ oniwaasu ijọ Baptisti agbegbe kan, nihin. N o lọ si ile iwosan. Nọọsi atijọ kan wa nigbana, o gbe ni Howard Park. Nko mọ boya o si wa nibẹ tabi rara. Ni ile iwosan naa. O maa n sọ fun awọn alaisan, Pe, "Bayi, ara yin yoo ya. Bayi, ara yin yoo ya." Pe, "Oniwaasu ijọ Baptisti kekere yẹn mbọ lati gbadura fun yin." Ṣe ẹ rii .... O jẹ igbati a ṣẹṣẹ bẹrẹ. Bi o ti ri nigbana niyi. Nisisiyi, yoo lọ kaakiri, lati agbegbe yi, lọ si gbogbo agbaye.

93 Ati nisisiyi, o fi àmì wọnyi fun mi lati rọpo imọ iwe ti nko ni. Nisisiyi, ti mo ba ni iru oye iwe ti awọn iranṣẹ Ọlọrun yooku ni (fun apẹrẹ, mo mọ ọkan, boya bi Arakunrin Neville, tabi Dokita Vayle, awọn kan ninu wọn), nko ni nilo lati ni eyi. Ṣugbọn mo ni lati ni-in, lati lee rọpo eyi, lati lee duro fun ohun ti nko ni niti imọ iwe. Mo ni lati ni awọn àmì naa .... Awọn àmì naa si ti ni ipá bi imọ iwe yoo ti ṣe. Ṣugbọn, ṣe ẹ rii, ti iwọ ko ba ni amuyẹ ti

o nilo, Ọlọrun ni agbara lati fi amuyẹ naa fun ọ ni ọna miran.

Bayi, ẹ ni igbagbọ, ki ẹ si gba mi gbọ. Bayi, mo fẹ ki ẹnikọọkan yin ṣe ileri fun Ọlọrun, nibiti ẹ n duro si. Nitoripe, ti ẹ ko bą se bẹẹ, ki yoo ran yin lọwọ. Mo fẹ ki ẹnikọọkan yin pa gbogbo iyemeji ti. Nigbati ẹ ba si wa si ori ila, nigbati mo ba gbadura fun yin, mo fẹ ki ẹ lọ ... Ẹ lee ma ri apẹrẹ kankan. Ṣugbọn Jesu ko sọ pe, “Njẹ iwọ ri i? Njẹ iwọ ni imọlara rẹ?” O wipe, “Njẹ iwọ gbagbọ? Njẹ iwọ gba a gbọ? Ti iwọ ba gbagbọ ....”

94 Bayi, mo ti sakiyesi eyi ni oju ọna. Mo gbadura fun awọn eniyan naa, awọn kan ninu wọn. Oun ko ni ṣe imẹmi-yatọ le wọn lori, wọn yoo lọ, wọn yoo si maa wipe, “Huh! Nko ri ohunkohun gba. Ko sọ ohukohun fun mi.” Eniyan bẹẹ ki i ri ohunkohun gba, pẹlu.

Ṣugbọn awọn kan ninu wọn lori ila naa yoo maa sọ pe, “O ṣeun, Oluwa. Mo gbaagbọ.” Awọn ni wọn maa n fi ẹ̀rí wọn ranṣẹ: “Ṣe o mọ, Arakunrin Branham, nko ni imọlara to yatọ fun ọpọlọpọ ọjọ [boya fun ọsẹ meji tabi mẹta tabi ju bẹẹlọ], ṣugbọn lojiji, mo bẹrẹ si ni imọlara aisan naa to n fi mi silẹ.” O si lọ, ṣe ẹ rii.

O lee sọ pe o gbagbọ. Oriṣi eniyan mẹta lo maa n wa si ipade - awọn alaigbagbọ, alafẹnujẹ-onigbagbọ, ati awọn onigbagbọ. Awọn kan ninu wọn maa n ṣe bi ẹnipe awọn gbagbọ: “Ah, bẹẹni, mo gbagbọ.” Ṣugbọn wọn ko gbagbọ. Ti o ba gbagbọ .... Mo fẹ bi ọ leere ibeere yi nisisiyi. Ti iwọ ba gba a gbọ, ko ṣe e ṣe fun ọ lati ma ni iwosan. Fetisilẹ. Jẹki n tun eyi sọ. Kọ se e ṣe fun ọ lati ma ni iwosan, ti iwọ ba gba a gbọ.

95 Lakọkọ, Ọrọ Ọlọrun lo fi aṣẹ naa fun-ni. Njẹ iwọ gba eyi gbọ? Ọrọ Ọlọrun lo kọkọ sọ bẹẹ. Iyẹn ju ohun gbogbo lọ. Ohun keji nipe, angẹli Oluwa ti fi idi rẹ mulẹ, àmì naa ti fi idi rẹ mulẹ. Ṣe bẹẹ ni? Nisisiyi, ko si ikuna kan nibikibi.

Ko si ikuna kan ninu Ọrọ Ọlọrun, ko lee sọ pe, “Mo ti kọkọ fun wọn ni iwosan, ṣugbọn bayi, mo mu kuro lọdọ wọn.” Mo fẹ ki ẹnikan fi iyẹn han mi. N o fi ibiti Jesu ti fi aṣẹ fun ijọ Rẹ lati maa gbadura fun awọn alaisan, adura igbagbọ yoo si gba alaisan la. Bayi, sọ fun mi, ibiti O ti sọ pe ko ni ṣẹlẹ mọ. Fihan mi ninu Bibeli, ṣe ẹ rii.

O wipe ni ọjọ ikẹhin, Oun yoo ṣe awọn ohun kan pato, yoo gbe awọn nkan wọnyi dide. Ẹ wo ohun ti o ti wa si imuṣẹ. O ti pa Ọrọ Rẹ mọ. Bayi, mo ti sọ fun yin pe O fi aṣẹ fun mi. Nisisiyi, gbogbo aye mọ, imọ-ijinlẹ mọ, angẹli Oluwa fi idi rẹ mulẹ, abajade ti o mu wa pẹlu ti fihan pe otitọ ni.

96 A n gbe ninu aye to n saisan. Ọpọlọpọ awọn eniyan ati nkan ni a ni lati gbadura fun. Mo ro o pe dajudaju ọna miran wa yatọ si ....

Arakunrin Moore sọ fun mi nigbakan pe .... Obinrin otoṣi kan wa to ŕakòró wọ inu gbọngan, arọ ni. Otoṣi kekere, o n gbiyanju lati wa si ibiti mo wa. Mo boju-wolẹ. Ọmọde naa bẹrẹ si sọkun. Koburu, wọn ko lee mu wa si ori ila, ko tilẹ ni kaadi adura. Nko mọ pe oun ni ọmọde aṣalẹ ana, Arakunrin Moore ati awọn yooku lo mu un kuro lori ila.

Ni ọjọ keji, a joko, a sọrọ nipa rẹ. O wipe, “Arakunrin Branham, iyẹn ba mi ninu jẹ.”

Mo wipe, “Inu rẹ bajẹ kẹ? Ki ni iwọ ro pe o ṣe si mi?”

Ṣe ẹ rii, ọmọdebinrin to jẹ arọ. Iyẹn mu mi lọkan. Eyi si jẹ nkan bi ọdun mẹwa sẹhin, ọmọdebinrin ni ilu Illinois. Irun ori rẹ dudu, oju rẹ jẹ alawọ omi kókò, o n rakoro, alaisan rọmọ-lapa, rọmọ-lẹsẹ to n gbiyanju lati de ibiti mo wa. Awọn asọna si ran-an lọwọ lati jẹki o joko si ori aga rẹ pada. O rakoro kuro lori aga rẹ ki o lee de ibiti mo wa. Eeṣe? Ọpọlọpọ ni mo lee ba sọrọ. Mo si ti fi awọn kan ninu wọn silẹ, mo mu un wa sibẹ laisi kaadi adura, ọpọlọpọ ni inu wọn ko ni dun, ṣe ẹ rii. Bẹẹ ni, nko lee ṣe e. Mo wipe, “Dajudaju, ọna miran wa lati ṣe e. O wumi ki n ti mọ ohun ti mo mọ nisisiyi nigbana. Ipo nkan ko ba ti yatọ. Ko ba ti yatọ lootọ.

97 Bayi, ẹnikọọkan yin, ohun kanṣoṣo ti ko ni jẹki ẹ gba iwosan ni ki ẹ ma gbagbọ.

Nisisiyi, ẹ jẹki a tẹriba.

Baba wa ọrun, nihin ni awọn afọju, arọ, awọn ti a n ni-lara, awọn alaisan, awọn ti jẹjẹrẹ n pa a lọ, awọn alaisan ọgbẹ-inu, awọn ti o ni oyun inu. Gbogbo wọn lo n duro si ori ila nihin, Oluwa. Mo ti waasu Ọrọ naa. Fun ọdun mejila, Iwọ ti fi idi rẹ mulẹ kaakiri agbaye. Mo ti beere fun idariji. Mo si mọ pe nko mọ mọ ṣe bẹẹ; mo ṣe bẹẹ nitoripe mo ro pe mo n ṣe ohun ti o tọ. Bayi, mo wa, Oluwa, mo tọ Ọ wa ni irẹlẹ, mo n bẹ Ọ lati fi ibukun si adura mi, pe nigbati mo ba gbadura fun awọn eniyan wọnyi, ki a wo gbogbo wọn san. Bukun igbagbọ wọn. Ran aigbagbọ wa lọwọ, Oluwa.

Ki ẹnikọọkan ni owurọ yi lee loye iran naa. Maṣe jẹki wọn o padanu ọkan ninu rẹ, ṣugbọn ki wọn o ri i pe o ba Iwe Mimọ mu. Ki a si ro nipa angẹli Oluwa lọhun, ni ibẹrẹ, ti o sọ pe, “Bi a ti fun Mose ni ẹbun meji ....” Ni ọdun meji sẹhin, O n mu Bibeli wa; pẹlu ọwọ kan to n sọkalẹ wa ti .... Bi eyiti O kọ akọle kan si ara ogiri ni

Babiloni. Ọwọ eniyan, irisi rẹ jọ bẹẹ, O tọka si Bibeli, si ori Iwe Mimọ yi kannaa, Pe, “Bi mo ṣe wa pẹlu Mose, bẹẹni Emi yoo wa pẹlu rẹ.” Baba, ohun niyi ni owurọ yi, ti a tan imọlẹ si i. A dupẹ lọwọ Rẹ fun eyi, Oluwa, Dari gbogbo asiṣe mi ji mi.

Ati nisisiyi, bi a ti n wọ inu ipade adura yi lọ, jẹki agbara Ọlọrun mu gbogbo alaisan to ba wa si ori ila larada. Mo n lọ bi iranṣẹ Rẹ, ki i ṣe pe mo n beere fun àmì-ororo ti o yatọ, tabi ohun kan to jẹ aramanda, ṣugbọn bi mo ṣe n mọ eyi, pe ni aye mi ni aṣẹ naa wa. Mo nlọ lati lo aṣẹ naa, ni orukọ Jesu Kristi.

98 Bayi, Arakunrin Neville, ti iwọ yoo ba duro sihin. Nisisiyi, pẹlu ẹbun yi, nko ni ta ororo le ẹnikẹni lori, ṣe ẹ rii. Ohun ti O sọ fun mi ni n o ṣe. Bi aṣẹ naa ti wi, “Mu ki awọn eniyan naa gba ọ gbọ, ki o si jẹ olootọ.” Njẹ ẹ gbagbọ? Lẹyinnaa mo jẹ olootọ. Ohun kan ni lati ṣẹlẹ!

Arakunrin Neville yoo dari wa ninu orin. Ki gbogbo yin maa gbadura ni idakẹjẹ nigbati mo n gbadura fun awọn alaisan [Arakunrin Neville bẹrẹ si kọrin “Ṣa a Ti Gbagbọ.”]

99 Jesu Oluwa, mo gbe ọwọ mi le obinrin ti o ni aisan okuta inu kidinrin yi, mo si ba wọn wi ni orukọ Jesu Kristi. Jẹki o lọ, ki a si mu un larada. Amin. Ohun kan ṣẹlẹ.

Ki ni iṣoro rẹ?

Oluwa, mo gbe ọwọ mi le arakunrin yi, pẹlu iṣoro aisan ṣétọ̀-ṣétọ̀, mo si ba agbara eṣu yi wi ni orukọ Jesu Kristi. Amin. O gbọdọ gba a. Gbagbọ.

Oluwa, mo gbe ọwọ mi le arabinrin mi ti o ni iṣoro ẹsẹ̀ ti o wú yi. Mo ba wiwu naa wi ni orukọ Jesu Kristi. Lọ, gba a gbọ, arabinrin, iwọ yoo si ri i.

Oluwa, pẹlu aisan ọkan ati awọn ailera yooku, to n yọ arabinrin mi lẹnu, mo gbe ọwọ mi le arabinrin mi, mo si ba aisan naa wi ni orukọ Jesu, nipasẹ aṣẹ mi.

Oluwa, mo ba aisan oju to n fọ lọ ati iṣoro ọkan yi wi laye obinrin yi, nipasẹ aṣẹ ti a fifun mi lati ọdọ Ọlọrun, lorukọ Jesu. Amin. O ni lati ri bẹẹ! Ara rẹ yoo ya. O ti ya. Amin. Mo gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan mi.

100 Otitọ ni, ti o ba ti to akoko rẹ lati lọ, iwọ yoo lọ botiwu-kori. O dara. Ṣugbọn, lakọkọ, ki O to sọ fun ọ, ti iwọ yoo ba jẹ olootọ, ti iwọ ko si ṣiyemeji rẹ, ara rẹ yoo ya. Bẹẹ gẹlẹ lori.

A ji Lasaru dide kuro ni ipo oku. O ku pada, ṣugbọn a ji i dide kuro ni ipo oku, lati fihan pe Ọlọrun pa Ọrọ Rẹ si awọn eniyan mọ! Jesu wipe, “Maria, iwọ ha gba eyi gbọ bi? Emi ni ajinde ati iye. A fi aṣẹ fun mi lati ọdọ Ọlọrun lati ji oku dide. Njẹ iwọ gba eyi gbọ?”

O wipe, “Bẹẹ ni, Oluwa. Mo gbagbọ pe Iwọ ni Ọmọ Ọlọrun to mbọ wa si aye.”

Jesu wipe, “Nibo ni ẹ sin in si?” Ṣe ẹ rii?

O ni lati ku pada. Ṣugbọn O ji i dide lati fihan pe Oun ni ajinde ati iye.

Ṣe ẹ rii. Ọlọrun maa n ṣe awọn nkan wọnyẹn, ohun gbogbo si wa ni ilana atoke wa. Ah, inu mi dun lati sọ eyi! Ohun gbogbo wa ni ilana pipe. Ti iwọ ba lee gbagbọ, ohun gbogbo ti o ba beere fun ni a o fifun ọ. O ni lati ri bẹẹ.

101 O dara, ẹ ṣa a maa tẹsiwaju ninu adura bayi, nigbati a n mu wọn wa si iwaju. Ki Ọlọrun bukun yin ...?

Jesu Oluwa, arabinrin wa n saisan pupọ, o ti n gbọ mi ti mo n duro nihin ti mo n waasu awọn ọrọ wọnyi. Jẹki ilọra iyemeji yi kuro laye gbogbo wọn, Oluwa. Jẹki wọn o dide, ki wọn o fi ori-oke ogbologbo ipo ojukan yi silẹ, ki wọn o lọ si Jordani. Oluwa. Ṣe e, Oluwa. Jẹki arabinrin mi rin ni ipa ọna yi bayi, lati wakati yi lọ, ki o maa gbagbọ pe Ọlọrun wo agọ ararẹ san. Ni orukọ Jesu. Lọ ni ọna rẹ ki o maa gbagbọ.

Ki Ọlọrun bukun ọ. Jesu Oluwa, fi ẹbẹ adura rẹ fun un nipa ọmọ rẹ obinrin ati ẹbi rẹ. Mo gbadura pe ni orukọ Jesu, yoo gba eyi, bi mo gbadura fun un, ti mo si lo igbagbọ mi nipasẹ bi mo ṣe gbe ọwọ lee. Ti nko ba gba Ọ gbọ, nko ni gbe ọwọ mi lee. Ti mo ba mọ pe Iwọ ko ni ṣe e, nko ni gbadura fun un. Ṣugbọn mo gbagbọ, Oluwa, oun pẹlu si gbagbọ, a si n da igbagbọ wa papọ, a n gbagbọ ninu orukọ Jesu. Amin.

102 Ki Ọlọrun bukun ọ, Pat. Oluwa fun awọn ọmọ rẹ iyebiye ti o n beere igbala fun. Ko lee gbọrọ daradara mọ. Dokita sọ pe kokoro katarati ti n wọ inu oju rẹ̀. O fẹ wa laaye fun ogo Ọlọrun. Ṣe eyi fun un, Oluwa, bi mo ṣe n beere fun awọn ẹbẹ wọnyi fun arakunrin mi. Amin.

Ki Ọlọrun bukun ọ, arakunrin. Maṣe siyemeji. Gbagbọ pe iwọ yoo ri ibeere rẹ gba.

Oluwa, obinrin kekere to n duro nihin fun ọmọkunrin rẹ̀ yi. N o fẹ ... ki Iwọ ... ohun to n pa a lara. O n lọ fun iru iṣẹ abẹ kan lori awọ ara rẹ. O si gbadura fun agọ ara rẹ ati igbala rẹ. O gbadura fun awọn ololufẹ rẹ. O beere fun iwosan kuro ninu ipo ẹgbọriri rẹ, Oluwa. O ti fẹ tuuka. Ọlọrun, mo gbadura pe Iwọ yoo fun un ni idahun ifẹ ọfẹ ọkan rẹ. Wo o san, mu kuro ninu inira rẹ, ki O si mu un larada. Ni orukọ Jesu ni mo gbadura igbagbọ yi fun un. Amin. Ki Ọlọrun bukun ọ, arabinrin. Lọ ki o si maa gbaagbọ. Ki Ọlọrun bukun ọ.

103 Oluwa, fun igbala awọn ololufẹ rẹ. Mo gbadura pe Iwọ yoo mu ẹbẹ ọkan rẹ sẹ, ni orukọ Jesu. Amin.

Gbagbọ nisisiyi, arabinrin, pe iwọ ti ri eyi gba, ati pe tirẹ ni. Ti iwọ ba gba a gbọ, o ni lati wa si imuṣẹ.

Fun Arakunrin wa Edgar Tyler. Ki Ọlọrun bukun ọkan rẹ! O dara, lati ilu Phoenix, Arizona. Ṣe ooru n mu nibẹ lọwọlọwọ?

Obinrin yẹn gba imularada rẹ ninu ipade mi. Nibo ni o ti wa? Ṣe ipinlẹ Phoenix ni iwọ ti wa, arabinrin? Iwọ ko wa lati .... O wà ni ilu Phonenix, ninu ipade.

Ki ni iwọ nfẹ ki O ṣe fun ọ, ṣa? Ki O mu aisan ikọ ṣeemi-ṣeemi kuro laye rẹ, arakunrin.

Ọlọrun ọwọn, bi arakunrin ọwọn yi ... ati nitori ajaga awọn eniyan. Mo gbadura pe Iwọ yoo fun un ni itusilẹ ; o wa lati ilu Phoenix, Arizona, ki a lee gbadura fun un, lati duro si ori ila, lati gbọ iwaasu naa, lati mu ọkan rẹ le. Oluwa, o da bi irubọ nla. Bẹẹ ni.

Ṣugbọn Ọba-binrin ti gusu naa wa, o rin irin-ajọ oṣu mẹta ni ẹyin rakunmi, ninu aginju Sahara, lati gbọ ọgbọn Solomọni; si kiyesi, Ẹniti o tobi ju Solomọni lọ wa nihin. Ẹmi Mimọ wa nihin, Ẹniti o ju Solomọni lọ.

Oluwa, mo gbadura pe Iwọ yoo wo o san niti inira agọ-ara rẹ yi. Fun un ni ifẹ ọkan rẹ. Jẹki o rin ni ọna ti a la fun un. Jẹki ire Ọlọrun simile e. Mo beere fun awọn ibukun yi fun arakunrin mi ni orukọ Jesu Kristi, Ọmọ Rẹ. Amin.

Ed, bi o ti nlọ, lọ pẹlu idahun adura rẹ. Tirẹ ni. Mo fifun ọ. Lọ ki o si gba a.

104 Arakunrin George. Gbogbo eniyan lo fẹẹ mọ George Wright. Eniyan melo lo ranti itan naa, nigbati o nku lọ laipẹ? Gbogbo awọn dokita lo fi i silẹ. Ararẹ wu bẹẹ, bẹẹ ni ẹjẹ didi wa ni ọkan rẹ. Ọpọlọpọ dokita lo ti pa a ti. Mo lọ lati gbadura fun un. Arakunrin Funk (O wa nihin nigbadiẹ sẹyin, mo gbagbọ) o wa pẹlu mi nibẹ ni aṣalẹ ọjọ naa. O joko si ori oke nibẹ, mo ṣe bi ẹnipe mo nlọ si oko-ọdẹ.

Mo fẹ sọ eyi fun ijọ nisisiyi pe, mo ni lati sọ awọn ohun kan to ti nlọ lọwọ. Ni ọpọlọpọ igba ti ẹ ba ro pe mo n dẹ̀gbẹ́, nko dẹ̀gbẹ́. O kan jẹ awawi lati mu ki awọn eniyan ma tẹle mi ni. Mo ni lati lọ sibẹ, ki n si da wa pẹlu Ọlọrun. Nko lọ lati dẹ́gbẹ nikan ẹyin ọrẹ. Bẹẹni, mo n dẹgbẹ, ṣugbọn ki i ṣe iru ọdẹ siṣe bẹẹ.

Mo joko si ori oke naa. Bayi, si mo n lọ lati dẹgbẹ ehoro. Mo lọ si iha ile, mo si na ọwọ mi si ile, mo si gbadura, mo gbadura. Mo n ku lọ! Ẹmi Mimọ ba mi sọrọ ni aṣalẹ ọjọ kan, “Ọkan ninu awọn eniyan wọnyi wa lati sọọsi kan ti ko gbagbọ pe iwosan latọrunwa tọna.”

Oniwaasu kan wa si ile rẹ nigba diẹ sẹyin, o si gbiyanju lati ba mi ṣe itakurọsọ kan nibẹ. Ọpọlọpọ ẹyin eniyan nihin ni ẹ wa nibẹ ni aṣalẹ ọjọ naa. Ṣe ẹ mọ ibiti ọkunrin naa ti fẹẹ lee ju irori pipe rẹ nu? Bayi, nikẹhin, o n gbiyanju lati gba Ẹmi Mimọ. [Arakunrin Wright sọ pe, “Nibiti o ti sọ pe emi ni ọrẹ rẹ ti o daraju ti o ni, lootọ.”] Ronu nipa eyi.

105 Eniyan ti o duro sibẹ lati ba mi ṣe itakurọsọ, ti o si sọ pe, “Lakọkọ, mo fẹ sọ fun ọ pe, ti eṣu ni iwọ i ṣe.”

Mo wipe, “Mo dariji ọ nitoripe iwọ ko mọ ohun ti iwọ n sọ.”

Lẹyinnaa, o wo yika, o si sọ pe, “Mo mọ pe iwọ ni Ẹmi Kristi.”

Mo wipe, “Mo jẹ ti eṣu ni iṣẹju diẹ sẹyin, mo si jẹ ti Kristi bayi. Ewo ni mo jẹ nibẹ?” Nitorina bayi .... Ohun buburu kan ti ṣẹlẹ.

Ọkunrin yi wa ni oju iku, ọkunrin yi si fi ṣe ẹlẹya, pe, “Bayi, lọ pe oluwosan atoke-wa rẹ.”

Mo si wa ni Lexington, ni ilu Kentucky, nibiti a ti mu obinrin kan larada kuro ninu aisan jẹjẹrẹ. Ninu iran kan, ti Oluwa fihan mi, O pada wa ni owurọ ọjọ naa ni nkan bi agogo marun owurọ, O fihan mi pe .... “Iwọ yoo bọ Arakunrin George Wright lọwọ, yoo maa bọ wa si ile Ijọsin, yoo wa sihin, yoo si bọ ọ lọwọ. Ọkunrin ti o si fi i ṣe yẹyẹ, oun ni yoo gbe iboji rẹ.” Nko mọ, nko mọ pe ó gbẹ iboji rẹ.

106 Mo pe Arabinrin Wright. O ni lati wa nibikan nihin. Bẹẹ ni. Mo pe Arabinrin Wright, mo sọ pe, “Mo ni 'Bayi ni Oluwa wi.” Bẹẹ ni. Iru awọn iran ti mo fẹ maa ri niyi lati isisiyi lọ; Mo sọ ọrọ kan fun ẹnikan, o pada wa. Mo

wipe, "Arakunrin George yoo gbẹ iboji ọkunrin yẹn, tabi ki o wa nibi iboji ọkunrin naa, eyito n fi i ṣe ẹlẹya. Yoo si wa si ile Ijọsin, n o si bọ ọ lọwọ." Ẹjẹ ti o di si ọkan Arakunrin George fi i silẹ.

Ni nkan bi oṣu kan si meji lẹyinna, mo pada wa. O si maa n, o fẹ ẹ jẹ igba gbogbo lo maa n wa sihin. Ṣugbọn ni owurọ ọjọ naa, o wa sihin. Mo ni apejọpọ kan, ti o wipe, "Wo o, wo o, wo o, nihin ni o wa lati bọ mi lọwọ, bi mo ti ri i ninu iran naa gẹlẹ."

Oun niyi loni. O jẹ [Arakunrin Wright sọ pe, "ni ọdun mẹsan sẹhin"] ọdun mẹsan sẹhin. ["Mo ni ẹjẹ dídì mẹsan to sẹku."] Ẹjẹ dídì mẹsan, ni ọdun mẹsan sẹyin!

107 Wayio, mo gbọ Arabinrin Hickerson ... Ṣe Arakunrin Hickerson wa nihin loni? Ara rẹ ti ya, o dara bẹẹ. O ni ẹjẹ dídì pẹlu, ọpọlọpọ wọn ninu ẹsẹ̀ rẹ̀.

Bayi, o ni aisan aromo-leegun ni ọwọ rẹ.

Eyi ni ọmọbinrin rẹ, Arabinrin Hattie to n joko sọhun yẹn, lori ẹniti mo ṣe ijẹri nisisiyi pe iṣẹ iranṣẹ mi tuntun naa siṣẹ le lori, ni igba akọkọ fun eniyan. Bẹẹ ni, Arabinrin Hattie. Mo n wo o ti awọn ọmọ naa ba wa nihin ni owurọ yi, ṣe wọn wa pẹlu rẹ? [Arabinrin Hattie sọ pe, "Lẹyin lọhun."]

Nibo ni awọn ọmọ kunrin naa wa? Awọn mejeeji lo n joko sẹhin. Awọn ọmọkunrin mejeeji niyẹn. Iya wọn niyi, ọmọbinrin arakunrin wa. Ẹ na ọwọ yin soke ẹyin ọmọkunrin yi, ki wọn lee ri ẹniti ẹ jẹ. O dara, wọn duro si ẹyin. O jẹ iyanu, ṣe bẹẹ kọ, Orville? Dajudaju, bẹẹ lori.

108 O dara.

Arakunrin George. [Arakunrin Wright sọ pe, Ṣe o mọ, Arakunrin Bill, mo gbagbọ."] Mo mọ pe o gbagbọ. Mo si mọ, ni ọpọlọpọ igba, mo ti sun si iyara rẹ, ni oru, ti mo n wo ita lati inu fereṣe, mo n feti si ẹyẹ atijọ kan. Ni ọjọ kan a o lọ, Arakunrin George. Titi di igba naa, ki Ọlọrun wa pẹlu wa. Mo mọ pe yoo wa pẹlu wa. "Bẹẹ ni, bi mo tilẹ n rin laarin afonifoji ojiji iku, emi ki yoo bẹru ibi kan. Iwọ wa pẹlu mi." Ninu iran naa, nihin nigba diẹ sẹyin, nigbati mo ri awọn arugbo ti wọn ti parada si ọdọ, bẹẹni n o ṣe ri o lọjọ kan, ni pipe.

Baba wa ọrun, fi ibeere ọkan arakunrin wa fun un. Wo o san kuro ninu aisan aromoleegun yi. O ti n darugbo, Baba, mo si gbadura pe Iwọ yoo ran an lọwọ. Ran Arabinrin Wright ati Edith kekere lọwọ, ati gbogbo ẹbi wọn. Arabinrin Hattie ati awọn ọmọ rẹ, gbogbo awọn ololufẹ wọn. Wa pẹlu wọn, Baba. Mu ẹbẹ adura yi ṣẹ, bi mo ṣe beere fun un ni orukọ Jesu. Amin.

[Arakunrin George Wright sọ pe, "N o pe ẹni ọdun mọkandinlaadọrin."] Mọkandinlaadọrin. Ki Ọlọrun bukun ọ, Arakunrin Wright, ki o si fun ọ ni ọjọ pupọ si. Ẹ yin Oluwa.

109 Arakunrin Daulton. Akiika! Arakunrin kan niyi ti o ti ṣe iyebiye si mi. N o sọ ohun ti o ṣẹlẹ fun yin. Nko ni akoko lati lee sọ ọ tan. Iyawo rẹ mọ. O wipe oun ku lọ. Pẹlu aisan ipá-ọkan, ṣe bẹẹni, arabinrin? Ati siwaju ki Oluwa to fun un ni àlá kan, ti itumọ ala naa si wa. Nigbati aisan ọkan naa ṣe e, o duro siwaju rẹ, o si sọ pe, "Mo tako eyi!" Ọlọrun ti fi àlá kan fun un pe yoo ri bẹẹ, itumọ naa si wa. Dokita naa si n ro pe ọkunrin naa n ku lọ nigbana, oun si niyi laaye loni.

Jesu Oluwa, si arakunrin wa ọwọn, o wa ọkọ wa lati ọna jin-jin rere lati wa sibi ipade yi, ni owurọ yi. Ibadi rẹ̀ n yọ o lẹnu. Bi ọkọ̀, Oluwa, ẹya ara rẹ n gbó lọ, o n lọ silẹ, ṣugbọn, Iwọ Oluwa, jẹ okun rẹ. Iwọ ni okun wa. Fi okun si ibi ti ko lokun ni ibadi rẹ. Fi okun si gbogbo ibiti ailera wa, Oluwa. Ki O si fi imularada fun arakunrin wa, bi mo ṣe sure fun un ni orukọ Jesu Kristi, Ọmọ Rẹ. Amin.

Ki Ọlọrun bukun ọ, Arakunrin Daulton. Bẹ́ẹ́ni yoo ri.

110 O dara, arabinrin, ki ni iwọ n fẹ ki Oluwa ṣe fun ọ? [Arabinrin naa n ba Arakunrin Branham sọrọ.] Eeṣe, Arabinrin Daugherty! Ṣe Betty niyi? ["Emi ni."] Eeṣe, Betty, ki Ọlọrun bukun ọkan rẹ! Ta ni ko mọ Betty Daugherty ni ile ijọsin yi! Lori ọmọde yi bi iṣẹ iranṣẹ mi atijọ ti kọkọ siṣẹ. Eniyan melo lo ranti nipa ọrọ aṣọ naa?

Betty ni aisan ti a n pe ni "st Vitus dance." O si wa ni iru ipo ti ko ti ṣe bi eniyan mọ. Ko si dokita ti o lee ṣe ohunkohun fun un.

Mo si lọ si St. Louis. Ijọ yi da owo fun mi lati lọ, mo si ya aṣọ awọleke ẹnikan, wọn si da owo dọla mọkanla jọ fun mi, lati lọ gbadura fun ọmọdebinrin yi. O jẹ ọmọdebinrin nigbana, bi ọmọdebinrin to n joko sihin, ọmọdebinrin. Mo si duro (Ṣe Arakunrin Daugherty wa nihin? Ko si nihin.) mo si gbadura, mo gbadura, mo gbadura. Nko lee de ibikan. Ni opin, bi mo ṣe n joko si inu ọkọ Arakunrin Daugherty, mo ri iran kan lori ohun ti wọn ni lati ṣe.

O si ti tęle itọni iran naa bi Oluwa ti sọ pe ki o șe gęlę. Mo gbagbọ pe o tako ero ti wọn diẹ lakoko naa. Șugbọn o șe e ni ọna ti Oluwa sọ pe ki o gba șe e, ara Betty si ya. Nigba akọkọ ti mo rii, bi .... Daugherty kan wa ni opin ibusun kan, ati Arakunrin Daugherty ni odi-keji, ki o si fọ oju ọmọ naa ati ọwọ rę, ati bęębęę lọ, “bi mo șe wọ inu adura naa lọ, ”Baba wa ti mbę ni ọrun, ki a bọwọ fun orukọ Rę.“

111 Aisan katarati si ti kọlu Betty. Mo ni lati gbadura fun un ni igba diẹ sẹyin, ni ẹyin ile kan ni Chatauqua.

Betty, olufę, jęki a dojukọ eyi sii. Mo fę di ọwọ rę mu. Șe iwọ ti di afọju ni, Betty? [“Rara.”] Iwọ lee ri imọlę ọjọ ati okunkun aşalę. [“O dara.”] Ęni ọdun melo ni ọ bayi, Betty? [“Ọdun mejile-logun.”] Ọdun mejilelogun. O jẹ nkan bi ọmọ ọdun meje si mẹjọ nigbana. Arabinrin Daugherty, iwọ ti ni onfa to le pupọ, șe bęę kọ? Șe o mọ, Betty, mo ti maa n gbagbọ pe Ọlọrun ni ohun kan fun ọ lati șe. Mo si gbagbọ pe iditi ọrọ rę fi ri bayi niyi. Mo si gbagbọ pe ọta lo șe ohun buburu yi.

Bayi, șe o mọ eyi Betty. Ti mo ba ni agbara lati lọ sinu oju rę, ki n si mu awọn katarati naa kuro, n o șe bęę. [“Bęęni.'] Nko ni agbara lati șe bęę.

Șugbọn, Betty, ohun ti mo sọ fun ọ lakọkọ, otitọ ni, bi mo șe joko sihin, iwọ ati emi, bi arakunrin ati arabinrin ninu Kristi. Arakunrin Daugherty, baba rę ọwọn, ęniti i șe arakunrin aladun ti mo tii ni ri. Iya rę olufę nihin. Mo ti gbe ni ile yin, ę si ti fi ounję yin bọ mi, ati ohun gbogbo. Ę ti ri bayi, o jẹ arabinrin mi lootọ, nko si lee ję olootọ ju bi n o ti ję si Delores to n joko sęhin lọhun lọ.

112 Bayi, Ọlọrun șe ileri eyi, Betty. Mo fę fun ọ ni gbogbo ... Baba rę, ęnitisę oniwaasu, ati tọ ọ ninu ębi to n gbadura fun awọn alaisan. A ti gbadura fun ọ lọpọlọpọ igba. O ti de ipele kan ti o ti n re e kọja nigbamiran, ati siwa-sęhin, a si ti ju ìpéye rę nu. Nję ę loye ohun ti mo nsọ?

Akiika, Betty, iwọ ti di ọmọbinrin daradara, arẹwa. O jẹ ohun itiju lati ri pe oju rę fọ bi eyi. Șe Meda si wa ninu gbọngan? Iyawo mi fę ri ọ. Mo fę ki o ri ọ; Betty, o ti di arẹwa obinrin. Betty, iwọ jẹ arẹwa obinrin kekere. O ti jẹ ọmọbinrin daradara latilę wa.

Bayi, nję ohun kekere kan wa ni aye rę ti o kuna, Betty? Bayi, bi dokita kan yoo ti șe ayęwo ara rę, mo fę wo ọkan rę. Nję iwọ ti ja Ọlọrun kulę nibikibi, Betty? Ti ibikan ba wa ti o ti ja Ọlọrun kulę, jęwọ ẹ̀sẹ̀ rę si i: Oluwa, ti Iwọ yoo ba mu mi larada lęękansi, n o șe yatọ.“

113 [Betty Daugherty n ba Arakunrin Branham sọrọ.]

Akiika, ohun to sajeji niyi. Jęki a wo o bayi. Bayi, nko mọ pe Betty Daugherty yoo wa ninu ipade yi. Șugbọn ęni akọkọ ti mo șe imęmi-yatọ fun ni Betty Daugherty. Oun niyi lęękansii, ninu ipade akọkọ fun ișę iranșę mi tuntun.

O mọ nigbana, ohun ti mo n sọrọ le lori. Nko fę bẹrẹ imęmi-yatọ yẹn lęękansii, nitoripe lori ila ... Șugbọn o sọ ohun ti o yęki o sọ nisisiyi. A kun un fun Ęmi Mimọ ni St. Louis. Gęgę bi Majęsin obinrin, ọmọde, boya o ti șe ohun ti ko yęki o șe. Tani ko ti șę? Tani ko șe asișe ri? Ti kii bą se ore-ọfę, gbogbo wa ti șegbe. Ti iwọ ba si șetan lati jęwọ ikuna rę, olododo ni Ọlọrun lati dari ęșę rę ji ọ.

114 Mo n gbe igbagbọ mi soke bayi. Oluwa, mo mu ọmọbinrin yi tọ Ọ wa. Mo n gbe ọwọ mi le oju rę. Mo n ba kokoro katarati yi wi, mo si gbagbọ pe awọn oju mejeeji yoo riran pada. Jęki agbara Ọlọrun alaye, Ęmi Mimọ naa, ki O fun Betty ni iriran rę pada, bi mo șe gbadura yi nigbati imisi igbagbọ wa lori mi. Lorukọ Jesu Kristi, Ọmọ Ọlọrun. Jęki n bọwọ pęlu arabinrin mi lęękansi nibikan, loni, lọla, tabi nigbakigba ti o lee jẹ lęękansi, ki awọn oju kedere naa si wo mi, ki o sọ pe, “Arakunrin Branham, mo lee riran bi ti atęyinwa…”

Nję iwọ gba eyi gbọ, Arabinrin Daugherty? Nigbana, yoo șęlę bęę!

Oluwa, ni orukọ Jesu, Ọmọ Ọlọrun, fifun arabinrin wa, ębę ọkan rę, bi o ti șetan lati gbọ lati ọdọ Rę. Jęki agbara ti o wo Betty Daugherty san lakọkọ, ati lęękeji yi pęlu, jęki o wo arabinrin wa san, lorukọ Jesu. Amin.

115 Arakunrin ... [Arakunrin naa ba Arakunrin Branham sọrọ] Arakunrin wa nfę lati ni igbala. Nję iwọ gba Jesu Kristi gęgę bi Olugbala rę?

Lorukọ Jesu Kristi, jęki gbogbo ębi ẹ̀ṣẹ́ kuro ninu ęri-ọkan arakunrin yi. Jęki arakunrin wa, lati isisiyi lọ, aye rę ti di Kristęni, ni orukọ Jesu Kristi.

Kọju si apejọpọ yi, ki o si sọ pe, “Mo gba Jesu gęgę bi Olugbala mi.” Nisisiyi ti o layọ pe ẹ̀ṣẹ̀ oun ti lọ nipasę ęję Jesu Kristi! Ohun ti a fęran niyi, amin, iwosan kikun, nipasę ìnà Rę .... Oluwa, fi idaniloju igbala obinrin yi fun un. Ni orukọ Jesu Kristi, o ni lati gba a gbọ. Maa lọ, ki o si maa gbagbọ bayi. Mașe siyemeji.

116 Pęlu eyi, mo șe așeyọri pupọ ni owurọ yi - nipasę iwaasu ti mo ti șe ati awọn nkan bi mo ti mọ to, mo ti

tẹle aṣẹ naa - mo ti ṣe pupọ ni owurọ yi ju bi mo ti ṣe lọ ni nkan bi ọdun marun sẹyin, nitoripe mo ti mọ ohun ti ṣe ifẹ Ọlọrun.

Bayi, o lee jẹ ohun ti o sọrọ fun mi lati ti inu iṣẹ iranṣẹ kan bọ si omiiran. Ṣugbọn ko yi ìpè pada, o kan mu ki iṣẹ iranṣẹ kannaa lọ si ipele giga ni. O jẹ aṣẹ ibẹrẹ pẹpẹ. Awọn nkan miran wọnyi ti n dagba lori iyẹn. Akoko naa niyi.

Pẹlu gbogbo ọkan mi, mo n gbagbọ fun ẹnikọọkan ti mo ti gbadura fun. Mo gbagbọ pe a o mu wọn larada. Ati pẹlu gbogbo ẹri ti a ni, ohun gbogbo ti Ọlọrun ni lati fihan, ni ọdun si ọdun, niti ẹri ti ko lee kuna, niti Bibeli to wa laaye bi ti igbaani, ba wo ni yoo ṣe kuna? Ko lee kuna rara.

117 Bayi, ọna kanṣoṣo lo wa lati mu ki o kuna, eyi ni fun iwọ lati ma gbaagbọ. Ti Jesu ba duro sihin funra Rẹ, ki O si gbadura fun ọ, ki O sị se ohun kannaa ti a ti ṣe ni owurọ yi, ohun ti yoo ṣẹlẹ ko lee ju odiwọn iṣẹ iyanu ti iwọ yoo ri gba lọ, ti o ba lo odiwọn igbagbọ kannaa ti o lo ni owurọ yi. Nitoripe, emi kan jẹ aṣoju Rẹ ni. Emi jẹ ẹlẹṣẹ ti a gbala nipa ore ọfẹ, eniyan lasan bi tirẹ, eniyan ẹlẹran ara. Ṣugbọn Ọlọrun gbọdọ ni aṣoju kan nibikan. O si ti fihan nipa Ọrọ Rẹ. O ti fi idi eyi mulẹ nipasẹ iṣẹ iranṣẹ. O ti fihan nipasẹ angẹli Oluwa, ohun niyi. Bayi o ku si wa lọwọ lati gba a gbọ.

Ranti nisisiyi, bii ọmọde. Ti arun kan ba ti wa, ko si nibẹ mọ. Maṣe fiyesi apẹrẹ aisan naa mọ, ohunkohun ti o ba lodi si ohun ti a ti beere. Lọpọlọpọ igba ... Gbogbo ọmọ ti o ba tọ Ọlọrun wa, a gbọdọ dan an wo. A n dan wa wo, lati mọ boya a gba iyẹn gbọ tabi rara. Ẹ o si dojukọ ogun ati iṣoro, ki ẹ si ranti pe a n yan an lọ si iṣẹgun.

118 Ki Ọlọrun bukun yin. Mo fẹran yin. Ati nipa iranlọwọ Ọlọrun, mo nireti pe yoo fun mi ni iranlọwọ lati sin yin gẹgẹ bi iranṣẹ Rẹ fun ọpọlọpọ ọdun sii, eyi ni adura mi. Ẹ gbadura fun mi.

Ati nisisiyi, ki ẹ ranti ni aṣalẹ yi: “Awọn Ohun Ifidimulẹ Marun ti Ijọ Ọlọrun Alaaye.” Titi di igbana, ẹ jẹki a duro lori ẹsẹ wa, fun iṣẹju diẹ.

Ah, njẹ isin iribọmi wa? [Arakunrin Neville sọ pe, “Mo gbagbọ pe o wa.”] Ah, isin iribọmi - ṣe ẹyin eniyan ti a fẹ ṣe iribọmi fun wa nihin? Ẹ na ọwọ yin soke, ẹnikẹni ti a fẹ ṣe iribọmi fun. Ẹnikan, ẹnimeji, ẹnimẹta ... Bẹẹni. Mo tọrọ aforiji pupọ, ẹyin ọrẹ.

Bayi, si awọn ti wọn ni lati lọ, n o tu wọn ka. Ki awọn yooku wọn duro fun baptisimu, awọn ti wọn fẹ ṣe iribọmi. A o ṣe isin iribọmi laipẹ.

119 Baba, Ọlọrun, maa ba awọn ti wọn ni lati lọ lọ, pẹlu ibukun Rẹ, ore-ọfẹ Rẹ, ki ore ọfẹ rẹ simile wọn, a n dupẹ lọwọ Rẹ fun oun gbogbo ti a ti ṣe ni owurọ yi, bi a ti n kuro lori oke naa, ti a n goke lọ. Oluwa, jẹki a goke lọ nipa gbogbo atẹgun ẹmi, titi ti a o fi de ijọba Ọlọrun. Ṣe e, Oluwa. Wa pẹlu wa bayi. Dari ẹ̀ṣẹ̀ wa ji wa, awọn ti wọn duro ki a lee ṣe baptisimu fun wọn, fun imukuro ẹ̀ṣẹ̀ wọn, ni orukọ Jesu Kristi. Jẹki a fi awọn nkan wọnyi fun wa.

Ko wa jọ papọ lẹẹkansi laṣalẹ yi. Jẹki agbara Rẹ ati ibukun Rẹ wa lori wa laṣalẹ yi. Jẹki a ni aṣalẹ rere ni alẹ́ yi. Jẹki ọpọlọpọ ti o wa ni ipo iporuru gba itọsọna Ọlọrun ni aṣalẹ yi. Ṣe e, Baba, nitoriti a beere ni orukọ Jesu. Amin.

O dara, ẹ lee joko nisisiyi, ti ẹ ba fẹ, nigbati a n murasilẹ fun isin iribọmi.

MESSAGE hub online

Ìwàásù lati ẹnu
William Marrion Branham
"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7

www.messagehub.info